Public Disclosure Authorized

Public Disclosure Authorized

E4830 v2

# Ilé-Iṣẹ́ Ìjọba Àpapọ̀ tó ń rí sí Ọ̀rọ̀ Iṣẹ́-Àgbẹ̀ àti Ìdàgbàsókè Ìgbèríko

## Àkànṣe-Iṣẹ́ lórí Irè-Oko tó máa ń jẹ́ Lílò Lóòrèkóòrè

## Ètò Ìlànà Ìbójútó Àyíká àti Àwùjọ

## ÌSỌNÍṢÓKÍ ÌMÚṢẸ́ṢE

## ÌSỌNÍṢÓKÍ ÌMÚṢẸ́ṢE

### Ọ̀rọ̀ Ìpìlẹ̀

Ó ti fojúhàn sí Ìjọba àpapọ̀ orílẹ̀-èdè Nàìjíríà pé kíkó oǹjẹ́ wọlé lákòójù wà lára àwọn ohun tó máa ń ṣokùnfà bí iyì orí owó wa ṣe máa ń dínkù àti bí ó ṣe máa ń fẹ̀dí orílẹ̀-èdè wa síta ní ọjà ágbáyé. Ìwà kí á máa gbáralé kíkó oǹjẹ wọlé yìí, àti ewu tó wà nínú ẹ̀ fún ètò ìpèsè oǹjẹ, nígbà tó jẹ́ pé àwọn orílẹ̀-èdè tó ń ta oǹjẹ síta pàápàá ń ṣètò bí oǹjẹ ṣe máa wà lọ́pọ̀ yañturu, kò bójúmu rárá, kò sì dára fún ètò ọrọ̀-ajé tàbí ètò ìṣèlú wa. Èyí ni ó ṣe okùnfà bí Ìjọba àpapọ̀ ṣe gbé àwọn ìgbésẹ̀ tó yẹ. Lára àwọn ìgbésẹ̀ bẹ́ẹ̀ ni Ètò Ìsọdọ̀tun Iṣẹ́-Àgbẹ̀ (ATA). Ètò ATA yìí ń ṣàgbéyẹ̀wò àwọn ìdènà tó jẹ́ àdámọ̀ fún ẹ̀ka iṣẹ́ àgbẹ̀ pẹ̀lú èròǹgbà àtiṣàfihàn àwọn ọ̀pọ̀ àǹfààní tó wà nídìí ẹ̀ nípa sísọ àwọn ètò iṣẹ́-àgbẹ̀ tí ìjọba ń darí di èyí tí àwọn ilé-iṣẹ́ àdáni yóò máa darí.

Ní ọ̀nà àti mú èròǹgbà yí ṣẹ, ilé-iṣẹ́ Ìjọba Àpapọ̀ tó ń rí sí ọ̀rọ̀ iṣẹ́-àgbẹ̀ àti ìdàgbàsókè ìgbèríko (FMARD) pẹ̀lú ìfọwọ́sowọ́pọ̀ Ìjọba Ìpínlẹ̀ Kogí àti ìgbèrò àtìlẹyìn Báǹkì Àgbáyé, tí ṣètò igba ó lé láàádọ́ta (250ha)sare oko fún ìdásílẹ̀ Agbègbè Ìṣètò Irè-Oko tó máa ń jẹ́ Lílò Lóòrèkóòrè (SCPZ), àti ọ̀kẹ́ mẹ́rìila sare oko (280,000ha)àyíká SCPZ fún Agbègbè okoòwò ajẹmọ́ṣẹ́-àgbẹ̀ tó jẹ́ ti etílé (ABIR), èyítí àwọn irè-oko tó wúlò fún ìpèsè àwọn ohun-èlò ní àwọn ilé-iṣẹ́ tí a dá sílẹ̀ ní agbègbè SCPZ.

Ohun tó jẹ́ bí ètò gbòógì fún ABIR àti SCPZ ṣàfikún fún èròǹgbà ATA nípa wíwá ọ̀nà láti darí àwọn owó ìdáṣẹ́sílẹ̀ sí àwọn ohun-èlò àwùjọ, àti láti fagbára fún àwọn ètò àti ìlànà ìdáṣẹ́sílẹ̀ ní agbègbè tí a lè pè ní "agbègbè okòòwò". Èyí yóò tún jẹ́ kí ìfigagbága wà láàrin àwọn ilé-iṣẹ́ tó ń ṣẹ̀dá àwọn ohun-èlò. Èyí yóò túbọ̀ ṣèmúgbòòrò ìfigagbága ìlànà ìnáwó láàrin àwọn onílé-iṣẹ́ tó ń pèsè ohun-ọ̀gbìn ní orílẹ̀-èdè Nàìjíríà; yóò mú ìdínkù bá níná ojú-owó àti owó iṣẹ́, àti láti jẹ́ kí àwọn ohun-èlò yìí tó gbangbaá sùn lọ́yẹ́ tí wọ́n bá dórí igbá tán, yálà nílẹ̀ yí tàbí lókè-òkun.

Síwájú sí i, ètò SCPZ, gẹ́gẹ́ bí Ìjọba Àpapọ̀ ṣe là á kalẹ̀, dá lórí ìlànà mẹ́ta wọ̀nyí: (i) ìmú ìlànà ọ̀tun bá àjọṣepọ̀ nípa ṣíṣàbẹ̀wò sí ìdíwọ́ tó ń wà fún àwọn ohun àlùmọ́nì inú omi àti ti orí ilẹ̀ àti mímú ìbáṣepọ̀ bá àwọn ọja; (ii) ìpèsè agbègbè iṣẹ́ tó pọ̀jú owó, èyí tí yóò dín owó ìdókòòwò kù, àti (iii) ìṣàmúlo ìlànà àwọn onísẹ́ aládàáni. Èyí ní àwọn ìlànà iṣẹ́ tí à ń ṣọ: (i) ìbáṣepọ̀ pẹ̀lú àwọn onísẹ́ aláàdáni tí yóò mú ìdàgbàsókè bá ètò ọrọ̀-ajé; (ii) ìṣàmúlò ìlànà àjọṣepọ̀ tó fọwọ́kọ́wọ́; (iii) ètò ìdarí tí yóò jẹ́ aládàáṣe, èyí tí ìjọba yóò ṣàtìlẹyìn fún àti ti àwọn oníléeṣẹ́ aládàáni.

**Èròǹgbà Ìdàgbàsókè Iṣẹ́ (PDO) àti Àwọn Ohun-Èlò Okòòwò tó Hàn Kedere fún Àkànṣe-Iṣẹ́**

Èròǹgbà Ìdàgbàsókè Iṣẹ́ (PDO) wà láti ṣàtìlẹyìn fún ìdàgb̀sókè ìpèsè àwọn ohun àjẹmọ́ṣẹ́-àgbẹ̀ àti ìbuyìkún àwọn àgbẹ̀ alábọ́dé àti àwọn tó pọwọ́ lé wọn nípa ìfilọ́lẹ̀ ìbáṣepọ̀ okòòwò tó mọ́yánlórí láàrin àwọn oníṣẹ́ aládàáni àti àwọn ti ìjọba fún àwọn okòòwò ajẹmọ́ṣẹ́-àgbẹ̀.

Iṣẹ́-Àkànṣè náà ní òpó mẹ́rin:

- Òpó kìíní: Ìpèsè àtìlẹyìn fún ìdàgbàsókè àwọn ohun-èlò àwùjọ fún SCPZ tó jẹ́ ti Alape.
- Òpó Kejì: Ìpèsè àtìlẹyìn fún ìbáṣepọ̀ àwọn àgbẹ̀ àti okòọ̀ọwò ajẹmọ́ṣẹ́-àgbẹ̀ àti fún àǹfààní tó wà lójúnà iyì tó wà nínú àjọṣepọ̀.
- Òpó Kẹta: Ìdàgbàsókè àwọn ilé-iṣẹ́ ní SCPZ
- Òpó Kẹrin: Ìbójútó àti ìdarí àkànṣe-iṣẹ́.

## Àpèjúwe Agbègbè Iṣẹ́-Àkànṣe

Iṣẹ́-àkànṣe tí à ń gbèrò láti fi lọ́lẹ̀ yí yóò gba agbègbè ìjọba ìbílẹ̀ márùn-ún ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀ kọjá ní Ìpínlẹ̀ Kogí, ní orílẹ̀-èdè Nàìjíríà. Àwọn ìjọba ìbílẹ̀ náà ni: Kàbà-Bunu, Lọ́kọ́ja, Okehi, Adavi àti Ìjùmú. Àpèjúwe bí iṣẹ́ yìí ṣe fara kọ́ àwọn ìjọba ìbílẹ̀ wọ̀nyí ni a ṣe sísàlẹ̀ yí:

**Agbègbè Kàbà-Bunu:** Kàbà-Bunu ni ìjọba ìbílẹ̀ tí ilẹ̀ tí a fẹ́ ṣèfilọ́lẹ̀ iṣẹ́-àkànṣe SCPZ ti Alape sí wà (igba ó lé láàádọ́tasare ilẹ̀: 250ha). Ó wà ní latitude 6.2888831 àti longitude 7.93077. Ó ní ilẹ̀ tó tó 2,757.57km$^2$;àwọn èèyàn tó ń gbé agbègbè náà sì jẹ́ 144, 579. Ọkùnrin jẹ́ 72,639, obìnrin sì jẹ́ 71,940. Ó pààlà pẹ̀lú Ìpínlẹ̀ Kwara àti Lọ́kọ́ja ní apá àríwá, ó pààlà pẹ̀lú Ìjùmú àti Mọ̀pà-Muru ní apá ìwọ̀-oòrùn. Ó pààlà pẹ̀lú Okehi ní apá gúsù àti Lọ́kọ́ja ní apá ìlà-oòrùn. Àwọn ìlú àti ìgbèríko tó wà ní Kàbà-Bunu tó wà ní agbègbè ètò ABIR ni Agbadu-Bunu, Ape àti Odo-Ape. Àwọn ìlú mìíràn ní àgbègbè yí ni Tivs, Ebira, Fulani, Tata, Apaa, Aiyede àti Ighun.

**Agbègbè Adavi:** Wọ́n ṣe ìdásílẹ̀ ìjọba ìbílẹ̀ Adavi láti ara ìjọba ìbílẹ̀ Okehi ní ọjọ́ kẹtàdínlọ́gbọ̀n, oṣù kẹjọ, ọdún 1991; nígbà yí náà ni wọ́n dá Ìpínlẹ̀ Kogi sílẹ̀. Ó wà láàrin látítúùdì 7015’ sí 8051’N àti lọ́ńgítúùdì60 sí 605’E. Ilẹ̀ ìjọba ìbílẹ̀ náà tó 730,608km$^2$; àwọn èèyàn agbègbè náà jẹ́ 217,219; ọkùnrin jẹ́ 108,891, obìnrin sì jẹ́ 108,328. Lára àwọn ìlú tó wà ní ìjọba ìbílẹ̀ náà ni Ogaminana, Kuroko, Inoziomi, Adavi-eba, Nagazi àti Osarangada. Ọ̀pọ̀ nìnú àwọn ìlú yìí ni ó wà ní ojú-ọ̀nà. Àwọn abúléko tó wà ní agbègbè ABIR ni oko Iresuare ní ìlú Osarangada. Ìdá mẹ́wàá nínú gbogbo àwọn èèyàn tó wà ní Osara-Ngada ni a lè rí ní Iresuare. Ohun kan pàtàkì tí a mọ̀ mọ́ Osara-Ngada ni Dáàmù Osaro èyí tí a ṣẹ̀dá láti ara odò Osaro.

**Agbègbè Lọ́kọ́ja:** Lọ́kọ́ja jẹ́ ìjọba ìbílẹ̀ kan ní Ìpínlẹ̀ Kogi, òun náà sì ni olú-ìlú Ìpínlẹ̀ kogí. Ó wà láàrin látítúùdì 09.18196 àti lọ́ńgítúùdì 007.17379. Ó pààlà pẹ̀lú Ìpínlẹ̀ Niger ní apá àríwá, Kaba-Bunu ní apá ìwọ̀-oòrùn, Kogí ní apá ìla-oòrùn àti Okehi àti Adavi ní apá gúsù. Àwọn ìpínlẹ̀ tó wà ní agbègbè náà ni Kwara àti Niger, àwọn ìjọba ìbílẹ̀ tó wà ní agbègbè yí ni Ajaòkuta, Adavi, Okehi àti Kaba/Bunu. Agbègbè ìjọba ìbílẹ̀ náà ní ilẹ̀ tó tó 3,180 km$^2$. Tí a bá fi ojú ètò àkọsílẹ̀ ìkànìyàn ọdún 2006 wò ó, àwọn èèyàn ìlú náà jẹ́ 196,643: Ọkùnrin ibẹ̀ jẹ́ 101,145, obìnrin sì jẹ́ 95,498. Ìlú Lọ́kọ́ja ló jẹ́ olú-ìlú ìjọba Gẹ̀ẹ́sì tó wà ní apá àríwá títí di ọdún 1914 tí wọ́n pa Gúsù àti Àríwá pọ̀ dí orílẹ̀-èdè kan. Ó jẹ́ ibùdó okòòwò fún agbègbè ajẹmọ́ṣẹ́-àgbẹ̀ yìí nítorí pé ó wà ní etíbèbè Odò Niger àti ti Benue, bẹ́ẹ̀ ni ó súnmọ́ olú-ìlú orílẹ̀-èdè Nàìjíríà, Àbújá. Àwọn ìlú tí iṣẹ́ àgbẹ̀ ti gbilẹ̀, tó wà lábẹ́ ìjọba ìbílẹ̀ Lọ́kọ́ja tí wọ́n sì tún wà ní agbègbè ABIR ni Oshokosho, Iwaa, Jakara, Ọbajana àti Apata.

**Agbègbè Ìjùmú:** Ìlú Ìjùmú wà láàrin látítúùdì 07.84340 àti lọ́ngítúùdì 05.95331. Ilẹ̀ ìlú náà jẹ́1.328.284km$^2$**,** iye àwọn èèyàn tó sì wà ní ìlú náà jẹ́ 118,593: ọkùnrin jẹ́ 59,582 nígbàtí iye obìnrin jẹ́ 59,011. Ìlú náà pààlà pẹ̀lú Mọpa-Muru àti Ìpínlẹ̀ Oǹdó ní apá ìwọ̀-oòrùn, Kaba-Bunu ní apá àríwá àti ìlà-oòrùn àti Pkehi ní apá Gúsù. Lára àwọn ilú tó wà ní agbègbè yí, tí wọ́n tún wà lábẹ́ ètò ABIR ni Ayégúnlẹ̀ àti Aiye.

**Agbègbè Okehi:** Ààrin gbùngbùn Ìpínlẹ̀ Kogí ní Okehi wà, ó sì wà láàrin látítúùdì 0.7 sí 07.600147 àti lọ́ńgítúùdì 0.6 sí 0.6.203570. Agbègbè méjì gbòógì ló wà lábẹ́ ìjọba ìbílẹ̀ yí: Ihima àti Eika. Orílẹ̀ mẹ́tàlá ló wà ní ìlú Ihima nígbàti orílẹ̀ mẹ́fà wà ní Eika. Àwọn ìlú tó wà ní Okehi, tó wà ní abẹ́ ètò ABIR ni Ohu, Iru, Irukura, àti Irukuochakoko. Ibùdó tí àwọn Fúlaní wà jẹ́ ibùdó kan pàtàkì tó wà fún àwọn àtọ̀húnrìnwà. Ilẹ̀ Okehi jẹ́ 672,582km$^2$ nígbà tí àwọn èèyàn inú ẹ̀ jẹ́ 223,574 (ọkùnrin 112,879 àti obìnrin 110,695). Ohun tí a mọ agbègbè yí mọ́ ni aṣọ-híhun, léyìí tí ọ̀pọ̀ àwọn obìnrin wọn máa ń ṣe. Èyí jẹ́ nǹkan bí ìdá márùn-ún nínú ìdá ọgọ́rùn-ún iṣẹ́-oojọ́ ní agbègbè náà.

**Èrèdí ESMF**

Ní àkókò ìgbáradì fún iṣẹ́-àkànṣe, kò tí ì sí òye kíkún lórí ibi tí a ó ṣè ìfilọ́lẹ̀ iṣẹ́ yìí sí ní pàtó. Nítorí náà, ó ṣe pàtàkì kí á ṣètò Ìlànà Ìbójútó Àyíká àti Àwùjọ láti le ṣè àtòjọ ètò ìdáṣẹ́sílẹ̀, ìlànà tó yẹ láti tẹ̀lé ká le rí i dájú pé bí á ṣe ṣètò CPZ wà ní ìbámu pẹ̀lú òfin EIA ní Orílẹ̀-èdè Nàìjíríà àti àkọsílẹ̀ Báńkì àgbáyé. Ètò ESMF yìí ṣàfihàn ìlànà tó ń rí sí ìtọ́jú àwùjọ àti ọ̀rọ̀ tó jẹ́ mọ́ ìbágbépọ̀ láwùjọ (E&S), ìṣètò àwọn ilé-iṣẹ́ lọ́nà tó yẹ àti àwọn ohun-èlò tí a nílò fún iṣẹ́. Èyí yóò rí i dájú pé àwọn àkànṣe-iṣẹ́ kéékèèké lábẹ́ SCPZ, tí a tò jọ, àwọn iṣẹ́ tó wọnú ara wọn lábẹ́ ètò ABIR, gẹ́gẹ́ bí wọ́n ṣe là á kalẹ̀ sínú àkọsílẹ̀, wà ní ìbámu pẹ̀lú àlàálẹ̀ E&S, tó sì tún wà ní ìbámu pẹ̀lú ìlànà ètò Báńkì Àgbáyé. Ètò ESMF yìí ṣàfihàn àwọn ìlànà ìpìlẹ̀ àti ọ̀nà ìgbàṣiṣẹ́ ní ọ̀nà tí àwọn

àkànṣe-iṣẹ́ kéékèèké yóò fi wà ní ìgbékalẹ̀ tí gbogbo àwọn tí ọ̀rọ̀ náà kàn yóò sì fara mọ́.

Àwọn èròǹgbà ètò ESMF mìíràn ni:

- Àgbéyẹ̀wò àwọn ohun tó le dàbí ewu nínú àwọn àkànṣe-iṣẹ́ kéékèèké àti àwọn ọ̀nà láti dẹ́kun wọn;
- Ìfilọ́lẹ̀ àwọn ìlànà tó fojúhàn fún ìṣètò E&S, àgbéyẹ̀wò, ìfọwọ́sí àti àgbékalẹ̀ àwọn àkànṣe-iṣẹ́ kéékèèké;
- Ìgbékalẹ̀ ètò ìṣàgbéyẹ̀wò ESA tí yóò jẹ́ lílò fún àwọn àkànṣẹ-iṣẹ́ kéékèèké; àti
- Àlàkalẹ̀ ojúṣe àti ìlànà ṣíṣe àkọsílẹ̀ tó ṣe pàtàkì, èyí tí yóò wà fún ìbójútó àwọn ètò E&S tó rọ̀mọ́ àwọn àkànṣe-iṣẹ́ kéékèèké.

Láti jẹ́ kí àwọn èròǹgbà ESMF yìí wá sí ìmúṣẹ, àwọn iṣẹ́ wọ̀nyí gbọdọ̀ jẹ́ mímúṣẹ:

- Iṣẹ́ kìíní: Ìgbéyẹ̀wò àti ìwòfín agbègbè
- Iṣẹ́ kejì: Ìṣẹ̀tò ìlànà àwùjọ àti ìbójútó ọ̀nà ìgbàmúṣẹ́ṣe
- Iṣẹ́ kẹta: Ipa dáadáa àti ipa burúkú tí ó le fojúhàn sí àwùjọ àti agbègbè
- Iṣẹ́ kẹrin: Ìtúpalẹ̀ àwọn ìlànà ìdènà tó ní í ṣe pẹ̀lú agbègbè àti àwùjọ
- Iṣẹ́ karùn-ún: Ìlànà láti bójútó ìdàgbàsókè àwọn ohun tó le dènà ewu tó leṣẹ̀lẹ̀ sí àwùjọ àti agbègbè iṣẹ́.
- Iṣẹ́ kẹfà: Ìlànà ìmúṣẹ́ṣe fún àwọn ilé-iṣẹ́
- Iṣẹ́ keje: Àwọn ohun-èlò ìkọ́ni; àti
- Iṣẹ́ kejọ: Ìfọ̀rọ̀lọ̀-àwùjọ

**Ìṣàmúlò ESMF àti Àwọn Irin-Iṣẹ́ Ààbò Mìíràn**

Ní àkókò ìgbáradì fún iṣẹ́-àkànṣe, kò tí ì sí òye kíkún lórí ibi tí a ó ṣè ìfilọ́lẹ̀ iṣẹ́ yìí sí ní pàtó. Nígbà tí a ti ṣètò yaágbóyaájù fún SCPZ àti ABIR ti Ìpínlẹ̀ Kogí, ibi pàtó tí a ó tí ṣe àwọn iṣẹ́ yìí kò tí ì jẹ́ mímọ̀ ní ẹ̀kúnrẹ́rẹ́. Bákan náà, ẹ̀kúnrẹ́rẹ́ àlàyé lórí ètò okoòwò gan-gan àti/tàbí ètò iṣẹ́-àkànṣe kékeré fún SCPZ àti ABIR kò tí ì sí nílẹ̀. Nítorí náà, ó ṣe pàtàkì fún ìlànà ìbójútó àyíká àti àwùjọ láti ṣe àtòjọ àwọn ọ̀nà tó yẹ ní gbígbà kí èrèdí SCPZ le wà ní ìbámu pẹ̀lú òfin EIA ní orílẹ̀-èdè Nàìjíríà àti ìlànà ajẹmáàbò Báńkì Àgbáyé. Wàyí o, ESMF yí kò ní ín lérò láti rí sí àkọsílẹ̀ láti ọwọ́ èèyàn kan(bó ti wù kó rí) nítorí pé ibi tí iṣẹ́ náà yóò ti jẹ́ ṣíṣe kò tí ì jẹ́ mímọ̀ ní àkókò yí.

ESMF yìí jẹ́ ohun tí a ṣètò gẹ́gẹ́ bí àkọsílẹ̀ adádúró ṣùgbọ́n ó tún fara kọ́ àwọn àkọsílẹ̀ adádúró méjì mìíràn [Ìlànà Ìtúndásílẹ̀ (RPF) àti Ètò Ìbójútó ìṣe àwọn kòkòrò tó ń ba àwọn nǹkan ọ̀gbìn jẹ́ (IPMP)], èyí tí a ṣètò pẹ̀lú iṣẹ́ àkànṣè yìí. Ètò

ESMF yìí yóò pèsè ìlànà tí yóò rí sí ewu tó le fojú hàn nípasẹ̀ iṣẹ́ àwùjọ àti ti àyíká, pẹ̀lú ìsọdọ̀tun àwọn ilẹ̀ tí à ń retí fún SCPZ àti ABIR. Ètò RPF ṣèfilọ́lẹ̀ ìlànà ìsọdọ̀tun àti ti gbà-má-bìínú, ìṣètò ilé-iṣẹ́ àti ìlànà àpèjúwe tí a ó lò láti rí sí ọ̀rọ̀ àwọn èèyàn tí iṣẹ́ àkànṣe yìí ṣe àkọ́bá kan tàbí òmíràn fún nípa gbígba ilẹ̀ wọn àti/tàbi ìfẹ̀tọ́-dunni, ìsénisíta tàbí àìní àǹfàní sí àwọn ohun-èlò ọrọ̀-ajé àti pé IPMP yóò ṣètò ìlànà tó mọ́yán lórí fún ìbójútó ọ̀rọ̀ àwọn kòkòrò tó ń ba nǹkan oko jẹ́ ní SCPZ àti àwọn ohun mìíràn tó farajọ ọ́, tó sì wọnú àwọn ìṣe ABIR

**Ọ̀nà ìgbàpalẹ̀mọ́ ètò ESMF**

A ti ṣètò ESMF yìí ní ìbámu pẹ̀lú ìlànà ètò ààbò Báǹkì Àgbàyé àti àkọsílẹ̀ lórí àgbéyẹ̀wò àwùjọ ti orílẹ̀-èdè Nàìjíríà, tí wọ́n sì ní àwọn iṣẹ́ wọ̀nyí nínú:

- Kíkó dátà jọ;
- Ìkópa nínú ìfọ̀rọ̀lọ̀ àwùjọ àti ìfọ̀rọ̀wérọ̀ pẹ̀lú abala ilé-iṣẹ́ tó yẹ, pẹ̀lú àwọn àjọ tí kì í ṣe ti ìjọba (àwọn NGO);
- Gbígbà àti ìtúpalẹ̀ dátà, tó ní í ṣe pẹ̀lú àgbéyẹ̀wò iṣẹ́ àwọn aṣáájú, àwòfín agbègbè àti ti àwùjọ pẹ̀lú àṣàjọ ètò-ẹ̀kọ́;
- Ìpinnu àwọn ohun tó le jẹ́ gẹ́gẹ́ bí ipá;
- Ìdámọ̀ àwọn ohun tó le dènà ewu; ìṣètò ìlànà ìgbáradì agbègbè àti àwùjọ;
- Àgbéyẹ̀wò àwọn ọ̀rọ̀ tí àwọn tọ́rọ̀ kàn wò; àti
- Ìpalẹ̀mọ́ àti àgbékalẹ̀ àkọsílẹ̀

**Àgbékalẹ̀ Ibi Tíṣẹ́ yóò mọ àti Ààlà Iṣẹ́.**

Ètò Ìlànà Ìbójútó Àyíká àti Àwùjọ (ESMF) ti jẹ́ fífilọ́lẹ̀ ní ìbámu pẹ̀lú àtìlẹyìn àkànṣẹ-iṣẹ́ fún agbègbè tí wọ́n ti ń ṣètò Irè-Oko tó máa ń jẹ́ Lílò Lóòrèkóòrè (SCPZ), èyí tó tún ní í ṣe pẹ̀lú kókó mẹ́rin tó wà lójú-ìwé ìsàlẹ̀. Ètò ESMF yí yóò jẹ́ lílò fún ètò ìlànà ìbójútó ewu agbègbè àti ti àwùjọ, ipa àti ìdènà ní Ìpínlẹ̀ Kogí, èyí tó jẹyọ láti àwọn wọ̀yí:

1. Àwọn okòòwò tí wọ́n ń fi owó àtìlẹyìn àkànṣe-iṣẹ́ SCPZ ṣe, pẹ̀lú àwọn ohun-èlò àwùjọ àti àwọn okòòwò mìíràn tí à ń gbèrò pé yóò jẹ́ ṣíṣe pẹ̀lú kókó kìíní àti ìkejì.
2. Ìfilọ́lẹ̀ àwọn agbègbè gbòógì tó jẹ́ ti SCPZ, èyí tó tó nǹkan bí i igba ó lé láàádọ́ta sare ilẹ̀-oko, pẹ̀lú àwọn okòòwò àdáni nípa ìyáhunlò ní àwọn agbègbè gbòógì ti SCPZ.
3. Ìdásílẹ̀ okòòwò láti ọwọ́ àwọn ayálẹ̀lò pẹ̀lú dídá oko àdáni sílẹ̀ ní agbègbè ABIR, èyí tó ní nǹkan bí i sare ilẹ̀ ẹgbẹ́rùn-ún lọ́nà ọgbọ̀n (a ò tí ì mọ iye tí yóò wọ̀n níparí)

Fún àwọn èrèdí ESMF yìí, òrọ̀ tí a pè ní "àkànṣe-iṣẹ́" yóò túmọ̀ sí àwọn kókó mẹ́ta tí a tò sókè yìí, bẹ́ẹ̀, "àkànṣe-iṣẹ́ kéékèèké", àti àwọn mìíràn yóò ní ìtumọ̀ bí a ṣe lò ó.

Ìjọba Ìpínlẹ̀ Kogí, síwájú sí i, ti fifẹ́ hàn sí ìṣàmúlò ESMF sí àwọn okòòwò tó níí ṣe pẹ̀lú ètò SCPZ ní sàkání ABIR, a ṣe èyí láti fi ìdọ́gba hàn nínú ọ̀nà ìgbàmójútó tó wà lábẹ́ ABIR. Ní ṣhókí, agbègbè àkànṣe-iṣẹ́ fún èrèdí ètò ESMF yìí yóò wà ní ibi tí ilé ìfowópamọ́sí wà, pẹ̀lú ọ̀gangan agbègbè ètò SCPZ, tó fi kan ti Cargill pẹ̀lú. Láfikún, ìlànà ètò ààbò Báńkì Àgbáyé náà yóò bá àwọn okòòwò tó ní í ṣe pẹ̀lú SCPZ ní sàkání ABIR àti àwọn okòòwò mìíràn nítorí ìdàpọ̀ tó ní í ṣe pẹ̀lú àjọṣepọ̀ tó ní àfojúsùn ìdàgbàsókè.

**Ìlànà Àwòdunjú fún Àyíká àti Àwùjọ**

Ìlànà àwòdunjú ni ìgbésẹ̀ kìíní fún ìmúṣiṣẹ́ ètò ESMF. Ìdí tí a ó fi ṣe èyí ni láti mọ àwọn àkànṣe-iṣẹ́ kéékèèké tí kò ní ewu kankan sí àwùjọ. A ti ṣàtòjọ àwọn ohun–èlò tí ó yẹ láti mú lọ́kùn-únkúndùn, léyìí tó wà ní ìbámu pẹ̀lú àlàkalẹ̀ ESMF. Àwọn àkànṣe-iṣẹ́ yìí tí wọ́n le ní ipa kan tàbí òmíràn lórí àwùjọ wà lára àwọn tí a fi sí abẹ́ ọ̀wọ́ yìí, a sì tipe irú àwọn iṣẹ́ báyìí ní "A". Nítorí náà, àwọn àkànṣẹ-iṣẹ́ kéékèèké yìí yóò ṣetán láti jẹ́ ṣíṣe níwọ̀n ìgbà tí a bá ti wò ó ní àwòfín, gẹ́gẹ́ bí òfin Àyíká Ìjọba Nàìjíríà ṣe là ó kalẹ̀ (ti ìjọba àpapọ̀ àti ti ìjọba ìpínlẹ̀), tó sì tún wà ní ìbámu pẹ̀lú ìlànà ààbò tí Báńkì Àgbàyé ti ṣètò kalẹ̀. Ìlànà àtitẹ̀lé àwọn àlàkalẹ̀ yìí ni ati ṣàfihàn sínú ètò iṣẹ́ yìí, àti àwọn ohun tó yẹ ní ṣíṣe ní ìbámi pẹ̀lú àwọn ohun-èlò tí a ti ṣàtòjọ wọn fún ìdámọ̀ tó rọrùn.

Àbájáde àwòdunjú àti iṣẹ́ ìgbéyẹ̀wò ọ̀wọ́ EA ni a ó fi ránṣẹ́ sí Báńkì Àgbáyé fún àtúnyẹ̀wò àti ìfọwọ́sí. Láfikún, gbogbo àwọn EA/ESMP tí a ti ṣètò la ó fí ránṣẹ́ sí Báńkì Àgbáyé fún àtúnyẹ̀wò láti rí i dájú pé iṣẹ́ náà wà níbàámu pẹ̀lú op4.01 àti àwọn ìlànà àti ètò ààbò mìíràn tó yẹ.

**Àwọn Ipa tí ó le wà lórí Agbègbè àti Àwùjọ àti Ìlànà tí a lè gbà Dènà Wọn**

A ṣètò àkànṣe-iṣẹ́ yìí láti ní àwọn ipa dáadáa lórí agbègbè àti àwùjọ. Lára irú àwọn ipa báyìí ní iṣẹ́ èrèdí akànṣe-iṣẹ́ yìí gan-an, àwọn ipa mìíràn sì jẹ́ ọ̀nà tí a ti gbà ṣètò iṣẹ́ ọ̀hún fún ìmúṣe àfojúsùn rẹ̀. Àwọn tí yóò jèrè iṣẹ́ náà ni àwọn ará ìgbèríko tí wọ́n jẹ́ aláìní, tí wọn ò sì gbé ní ẹ̀gbẹ́ títì. Ní pàtó, àwọn àǹfààní wọ̀nyí ló wà láti ara àkànṣe-iṣẹ́ yìí: ààbò lórí yẹ̀ẹ̀pẹ̀, ìgbèèrú owó orí iṣẹ́-àgbẹ̀ láti ara irè-oko àti ìṣedéédé lẹ́nu iṣẹ́-àgbẹ̀, ìpèsè oúnjẹ, ìdínkù ìṣẹ́, ìgbèèrú owó tó ń wọlé ní àwọn ìgbèríko àti ìdàgbàsókè ọrọ̀-ajé orílẹ̀-èdè, ìṣaralóore oúnjẹ, ìpèsè iṣẹ́ fún àwọn agbègbè tí iṣẹ́ náà wà, fífún àwọn àgbẹ̀ ní agbára tí kò níí ya akọ tàbí abo sọ́tọ̀, ìmúdàgbà àwọn ohun-èlò àwùjọ, ètò ìlera tó mọ́yánlórí, ìmúṣẹ ètò àti ìlànà ìsọdọ̀tun nípa iṣẹ́-àgbẹ̀ tó jẹ́ tí ìjọba àpapọ̀, abbl.

Láìsí àní-àní, ó jẹ́ èrò wa wí pé àkànṣe-iṣẹ́ yìí yóò ní àwọn ipa burúkú kọ̀ọ̀kan lórí agbègbè àti àwùjọ tí iṣẹ́ náà ti jẹ́ ṣíṣe. Àwọn ipa yìí ti jẹ́ mímọ̀, ṣùgbọ́n wọ́n tún ní àwọn ohun tó ní í ṣe pẹ̀lú ìgbèríko tí a ti fẹ́ ṣe iṣẹ́ náà gẹ́gẹ́ bó ṣe wà lórí àtẹ ES a àti b fún iṣẹ́-àgbẹ̀ àti ìlànà tó yẹ fún un, láìyọ ìdàgbàsókè ohun-èlò àwùjọ sílẹ̀. Nínú àwọn àtẹ yìí, àwọn ìlànà ètò ìdènà ewu ti jẹ́ fífihàn, a ó sì tún tepẹlẹ mọ́ ọn nípa ESIA/ESMP, èyí tí a ó ṣètò fún àkànṣe-iṣẹ́ kéékèèké nígbà tí a bá ti mọ àwọn àkóónú wọn.

**Àkójọpọ̀ Ipa Àwùjọ àti ti Àyíká**

Kò sí àwọn ewu tí a lè pè ní ewu ọlọ́jọ́-pípẹ́ tó le ṣẹlẹ̀ ní agbègbè àti àwùjọ àkànṣe-iṣẹ́ náà. Àmọ́ ṣá o, àkójọpọ̀ àwọn ewu tó wà nínú àwọn iṣẹ́tọ́ wà nílẹ̀, nínú àwọn iṣẹ́tí a fẹ́ ṣe, àti/tàbí nínú àwọn iṣẹ́ tí à ń gbèrò láti ṣe lọ́jọ́ iwájú, le ṣokùnfà ewu burúkú àti/tàbí ipa rere ní agbègbè àti ní àwùjọ, léyìí tó le má rí bẹ́ẹ̀ fún iṣẹ́ adádúró.

Àwọn àkójọpọ̀ ipa tí àkànṣe-iṣẹ́ yìí le ní tún le wà lórí àwọn agbègbè mìíràn tó ní ìbáṣepọ̀ pẹ̀lú agbègbè àkànṣe-iṣẹ́. Àmọ́ o, àwọn to dàbí ohun ìdènà ewu yìí yóò jẹ́ gbígbéyẹ̀wò láti le mọ bí ewu tí à ń retí lára àkànṣe-iṣẹ́ kéékèèké níwọ̀n ìgbà tí a ti ní ìmọ̀ tó kún nípa iṣẹ́ náà. Láfikún, àwòdunjú tí a fẹ́ wo àwọn àkànṣe-iṣẹ́ yìí pẹ̀lú iṣẹ́ ESIA/ESMP ní pàtó yóò fún wa ní àǹfààní ńlá láti lè mọ àwọn ewu tó ṣeé ṣe kó fojúhàn lẹ́nu iṣẹ́ náà.

| Àtẹ ES a: Ìṣọníṣókí àwọn ipa àti ìlànà SZPZ tí a lè gbà dènà (Àwọn ìṣe àti ètò tó níí ṣe pẹ̀lú iṣẹ́ àgbẹ̀) àwọn ohun-èlò | | |
|---|---|---|
| **Àwọn ohun tí a ní lérò láti ṣe** | **Àwọn ohun tí ó jẹ́ gẹ́gẹ́ bí ipa/tí ó mú wa lọ́kàn**. | |
| Àwọn iṣẹ́ àgbẹ̀, ìpèsè àwọn ohun-ọ̀gbìn tó níí ṣe pẹ̀lú igbó-ṣíṣán, ìtúnṣe àwọn pápá fún iṣẹ́ àgbẹ̀ àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. | **A. Agbègbè** | **B.** |
| | **<u>ohun abẹ̀mí àyíká</u>**<br>• Dídásí ọ̀rọ̀ nípa ìtọ́jú àwọn ohun abẹ̀mí àyíká ( ìyípadà tó ń dé bá àwọn ẹranko àti àwọn ewéko)<br>• Gbíngbin ẹ̀gẹ́ nìkan lè ṣèpalára fún ilẹ̀ oko.<br>• Ìdènà àti àìfàyè gba iná | • Má ṣe lo àwọn ilẹ̀ tó wà níbi tó léwu tàbí tí àwọn nǹkan agbègbè le pa lára;<br>• Fọ̀rọ̀lọ ẹ̀ká ilé-iṣẹ́ tó ń rí sí igbó-ṣíṣọ́ kó o tó pinnu ibi tó o fẹ́ lò<br>• Rí i dájú pé o ya ibi kan sọ́tọ̀, bí i kìlómítà kan láàrin igbó tí o ti fẹ́ ṣiṣẹ́, níbi tí o |

| | | |
|---|---|---|
| | | kò ní lò fún iṣẹ́ rárá lábẹ́ SCPZ/ABIR. Ṣètò ìkọ́ni fún àwọn ará ìlú láti mọ bí a ṣe lè dènà iná, àti bí a ṣe lè lo àwọṅ irin-iṣẹ́ tó yẹ.<br>• Ètò láti rí sí igi-gbígbìn nínú àwọn igbó tí kò ti sígi gbọ́dọ̀ jẹ́ kókó<br>• Yẹra fún pípa àwọṅ ẹran-ìgbẹ́. |
| | **<u>Àwọṅ Àlùmọ́nì inú Omi</u>**<br>• Síséomi tó ń ṣàn<br>• Ìsédò kékeré yóò dínà bí omi a ṣe máa jẹ́ lílò fún àwọn ará agbègbè.<br>• Irú ìsédò kékeré báyìí léwu fún ìlera<br>• Ọ̀rọ̀ lórí omi amọ́lóló | • Ya ibì kan sọ́tọ̀, tí yóò tó nǹkan bí i ìlàjì kìlómítà kan ní etídò tí yóò máa ṣiṣẹ́ asẹ́ fún àwọṅ ìdọ̀tí inú omi.<br>• Kí a tó ṣe ìsédò kékeré, a gbọ́dọ̀ ti wo àwọṅ ọ̀nà mìíràn tó ṣeé lò yàtọ̀, tí kò sì níí pa àwọn èèyàn lára.<br>• Irú ìsédò báyìí gbọdọ̀ tóbi díẹ̀ láti le gba ìgbọ̀nrìrì dúrò, èyí jẹ́ dandan nínú irú iṣẹ́ báyìí.<br>• Jẹ́ kí ọ̀rọ̀ ààbò gbogbo èèyàn wà ní oókan àyà láti ìbẹ̀rẹ̀ pẹ̀pẹ̀ iṣẹ́ yìí. |
| | **<u>Yẹ̀ẹ̀pẹ̀</u>**<br>• Gbíngbin ẹ̀gẹ́ ṣáá le jẹ́ kí gbogbo àwọn ọ̀rá ilẹ̀ máa dínkù, èyí tí a sì gbìn sí ẹ̀gbẹ́ òkè, kò níí sí ohun tí yóò dá àgbàrá dúró lórí rẹ̀.<br>• Ìyípadà nípa àwọn ọ̀rá inú ilẹ̀ (bí a ṣe lè ṣètọ́jú àwọn kábọ́ọ̀nì) | • Àrídájú ìtọ́jú yẹ̀ẹ̀pẹ̀/ohun-ọ̀gbìn lọ́nà tó dára<br>• Ìṣàmúlò ọ̀nà ìgbàtọ́jú àwọn ohun-ọ̀gbìn/yẹ̀ẹ̀pẹ̀ lọ́nà àti jẹ́ kí irè-oko pọ̀ síi tí kò sì níí wọ́ yẹ̀ẹ̀pẹ̀ ilẹ̀ lọ.<br>• Kí a máa ṣe àgbìnpọ̀ àwọn ohun-ọ̀gbìn bí i àgbàdo, ẹ̀pà, ẹ̀wà, ereé, ẹ̀gúsí àti elégédé.<br>• Má ṣe gbin nǹkan sí ibi |

| | | |
|---|---|---|
| | • Ìdènà awọn tó dàbí àtòjọ yẹ̀ẹ̀pẹ̀ àti ojú yẹ̀ẹ̀pẹ̀, èyí tó le ṣẹlẹ̀ nípa iṣẹ́ ọ̀gbìn náà. | gẹ̀rẹ́gẹ̀rẹ́<br>• Yàgò fún ìfọ́nkiri ajílẹ̀ |
| | **<u>Afẹ́fẹ́</u>**<br>• Ìdínkù afẹ́fẹ́ gidi nítorí ìrìnkèrindò ọkọ̀ tí o ń gbé irin-iṣẹ́ sókè-sódò.<br>• Ìjàǹbà tó le ṣẹlẹ̀ nínú afẹ́fẹ́ nípa sísun àwọn igbó tí a ti gé kalẹ̀. | • Ó yẹ ká rí i dájú pé à ń ṣàyẹ̀wò sí àwọn ọkọ̀ àti àwọn irin-iṣẹ́ mìíràn láti dín ewu tó wà nínú èéfín tó ń jáde nínú wọn kù.<br>• Ìdánilẹ́kọ̀ọ́ ṣíṣe fún àwọn awakọ̀ láti má ṣe sáré àsápojúdé, pàápàá ní ìgbàẹ̀ẹ̀rùn.<br>• Ìdínkù sísun àwọn ohun tó le fa ewu sínú afẹ́fẹ́.<br>• Àwọn igi tí a ge lulẹ̀ ṣeé lò gẹ́gẹ́ bí igi ìdáná tàbí eèkànàgbáwọlẹ̀. |
| | **<u>Ìyípadà Ojú-ọjọ́</u>**<br>• Ẹ̀gẹ́ jẹ́ ohun-ọ̀gbìn tó fara da ọ̀gbẹlẹ̀, àmọ́ ṣá, ọ̀gbẹlẹ̀ ọlọ́jọ́ pípẹ̀ le ṣe ìjàǹbá fún un, pàápàá tó bá ṣẹlẹ̀ ní kété lẹ́yìn tí a gbìn ín tán.<br>• ẹ̀gẹ́ a máa jẹrà tí omí bá rogún sí ojú kan kọjá ọ̀sẹ̀ kan. | • Kí á dúró de ìgbà òjò tí ọ̀gbẹlẹ̀ bá ṣẹlẹ̀ ká tó gbin ẹ̀gẹ́ tàbí kí á máa bu omi rin ín.<br>• Kí a gbin ẹ̀gẹ́ sórí ebè, èyí tí adágún omi kò níí le bàjẹ́.<br>• Kí a gba àwọn àgbẹ̀ níyànjú láti máa ṣàmúlò ọ̀nà ìgbàdáko tó le mú irè-oko pọ̀ sí i (èso, ewébẹ̀, abbl, kí àyè wà láàrin ọ̀gbìn wọn) àti àwọn nǹkan tó jẹ mọ́ ojú-ọjọ́ mìíràn (ìtúnṣe àwọn àlùmọ́nì inú ilẹ̀, abbl).<br>• Jẹ́ kí ọ̀nà ìgbàdáko bá ojú- |

| | | |
|---|---|---|
| | | ọjọ́ tó yẹ mu. |
| | **Ìlò Kẹ́míkà láti pa kòkòrò**<br>• Ewu tó le ṣekú pa àti èyí tí kò le pa àwọn ohun abẹ̀mí mìíràn;<br>• Ibùdó ìṣekẹ́míkà ìpakòkòrò- ìlò àwọn kẹ́míkà yìí ní àlòjù le mú kí àwọn kẹ́míkà ọ̀hún má lágbára lórí wọn mọ́.<br>• Àwọn kẹ́míkà tí omí bá ṣàn sínú omi láti orí ilẹ̀ le fa ewu ńlá.<br>• Ewu tó wà nínú kí àwọn èèyàn àti ẹranko máa fa òórùn àwọn kẹ́míkà yìí símú.<br>• Àìṣàmúlò àwọn kẹ́míkà wọ̀nyí lọ́nà tó tọ́ nípasẹ̀ ìwà àìbíkítà nígbà tí à ń lò ó lọ́wọ́ le fa àìsàn sí àgọ́ ara. | • Fàyè gba ìlò àwọn kẹ́míkà fún nǹkan-ọ̀gbìn tó bá ṣeé ṣe.<br>• Ìlò àwọn kẹ́míkà ìpakòkòrò òde-òní, èyí tí kò léwú fún àyíká (wo IPMP tí a ṣètò fún SCPZ àti ABIR)<br>• Kí a máa gbin ẹ̀wà sí àarin àwọn ohun ọ̀gbin mìíràn lóòrèkóòrè.<br>• Fífọ́n àwọn kẹ́míkà báyìí láìní gbèdéke kò ní í wáyé<br>• Àìfàyègba ìlò àwọn kẹ́míkà tó ń pa ewéko<br>• Ìṣètò ìkọ́ni fún àwọn àgbẹ̀ nípa lílo àwọn kẹ́míkà báyìí àti PPE<br>• Ìfilọ́lẹ̀ ètò ìwádìí lórí àwọn àrùn tó máa ń kọlu nǹkan ọ̀gbìn fún àwọn àgbẹ̀;<br>• Àwọn àjọ tó ń rí sí ìtọ́jú àyíká yóò máa ṣèrànwọ́ fún àwọn àgbẹ̀ nípa bó ṣe tọ́ láti máa lo àwọn kẹ́míkà báyìí. |
| | **Ìbójútó àwọn ìdọ̀tí**<br>• Àìbìkítà sí àwọn ìdọ̀tí àjìlẹ̀ àti ti kẹ́míkà mìíràn | • Láti pèsè ọ̀nà àtimáagba gorodóòmù lọ́wọ́ àwọn àgbaẹ̀.<br>• Ìfilọ́lẹ̀ ètò lórí ìtọ́jú àwọn ìdọ̀tí àti ọ̀nà tí ìdọ̀tí kò fi |

| | | |
|---|---|---|
| | | níípọ̀ lápọ̀jù. |
| | • **ÀWÙJỌ** | |
| | **<u>Ilè̩-gbígbà</u>**<br><br>• Ìlè̩-gbígbà àti ọ̀rọ̀ owó gbà-má-bìnú;<br>• Ìgbówólórí ilẹ̀, èyí tó le yọrí sí kí àwọn tí kò lówó má lágbára rè̩. | • Títè̩lé àwọn ìlànà tí a là kalẹ̀ nínú ètò ìṣíkúrò níbí kan lọ sí ibòmíràn.<br>• Kí ìfọ̀rọ̀lọ̀ agbègbè jé̩ dandan<br>• Kí á rí i dájú pé a yánjú gbogbo ọ̀rọ̀ tó níí̩ṣe pẹ̀lú ìṣíkúrò.<br>• Ṣọ́ra fún ọ̀rọ̀ àwọn ajagungbalẹ̀ àti iṣẹ́ wọn ní agbègbè<br>• Kí á mọ àwọn àgbẹ̀ ayálè̩lò, kí á sì fi orúkọ wọn sínú ètò SCPZ, tí ó bá sì ṣeé ṣe kí a pèsè ilẹ̀ burè púlọ́ọ̀tì kọ̀ọ̀kan fún wọn. |
| | **<u>Ìṣètò fún àwọn tí ó pàdánù ilẹ̀</u>**<br><br>• Ìpàdánù ilẹ̀ lásán àti ilẹ̀ oko<br>• Ìpàdánù iṣẹ́ (àwọn iṣẹ́ tó dálé orí ilẹ́)<br>• Lílé àwọn àgbẹ̀ alábọ́dé dànù<br>• Bíbèèrè ilẹ̀ fún oko-dída/ibùgbé nítorí ilẹ̀ kò pọ́ nílẹ̀ mọ́. | • Títè̩lé àwọn ìlànà tí a là kalẹ̀ nínú ètò ìṣíkúrò níbí kan lọ sí ibòmíràn.<br>• Kí á fún àwọn àgbẹ̀ tọ́rọ̀ kàn náà ní àǹfààní láti bẹ̀rẹ̀ iṣẹ́ wọn padà ní agbègbè mìíràn;<br>• Ìṣèrànwọ́ láti ṣègbélárugẹ àwọn ọgbọ́n tó yẹ ní lílò àti ìlò ẹ̀rọ̀ òde-òní kí irè-oko le túbọ̀ pọ̀ síi fún àwọn àgbẹ̀ adádúró àti àwọn tó wà papọ̀.<br>• Kí ìfọ̀rọ̀lọ̀ agbègbè jé̩ dandan |

| | | |
|---|---|---|
| | | • Kí á rí i dájú pé a yánjú gbogbo ọ̀rọ̀ tó nííṣe pẹ̀lú ìṣíkúrò.<br>• Ìpèsè ètò ìkọ́ni òde-òní fún àwọn agbègbè iṣẹ́ kí wọ́n le ní àǹfààní sí ọ̀tún àti òsì lórí ọ̀rọ̀ àkànṣe-iṣẹ́ SCPZ.<br>• Ṣàmúlò ẹgbẹ́ àwọn àgbẹ̀ tó wà, tí kò bá sì sí, kí á dá ẹgbẹ́ àwọn àgbẹ̀ ẹlẹ́gẹ̀ẹ́ sílẹ̀;<br>• Kí á buyì kún iṣẹ́-àgbẹ̀ ẹlẹ́gẹ̀ẹ́ nípa ìṣẹ̀dá àwọn ọjà ìgbèríkò tí yóò ní ìbáṣepọ̀ pẹ̀lú àwọn ibùdó ìpèsè nǹkan.<br>• Yẹra fún owó àbẹ̀tẹ́lẹ̀ rìbá |
| | **<u>Àṣà Ìbílẹ̀</u>**<br>• Wíwá àwọn nǹkan àdáyébá<br>• Ìdásí àwọn àṣà ìbílẹ̀ àti àṣà ìfidánimọ̀ | • Dídènà ewu nítorí àkànṣe-iṣẹ́<br>• Tẹ̀lé ètò tí a ti là kalẹ̀ fún wíwá àǹfààní lójúnà àwọn ohun-èlò ìbílẹ̀ (OP/BP 4.11) |
| | **<u>Aáwọ̀ àti Ìdojúkọ Àwùjọ</u>**<br>• Ìdènà ibùjẹ fún àwọn ẹran-ǹ-jẹ<br>• Yíya àwọn obìnrin tàbí àwọn aláàbọ̀-ara sọ́tọ̀. | • Ìfọ̀rọ̀lọ̀ àwùjọ nìgbà gbogbo<br>• Wá ọ̀nà ìgbàṣenǹkan láti ara ọgbọ́n àti ìmọ̀ àwọn ènìyàn agbègbè.<br>• Kí àwọn agbàṣẹ́ṣe máa ṣàmúlò àwọn ènìyàn agbègbè náà fún iṣẹ́ wọn.<br>• Àwọn ìlérí fún agbègbè gbọ́dọ̀ wà sí ìmúṣẹ, tí kò bá ṣeéṣe, kí wọ́n wá ọ̀nà àbáyọ̀ tó tọ̀nà.<br>• Ìdènà aáwọ̀ láàrin àwọn àgbẹ̀ àti àwọn tó ń kó ẹran jẹ̀, kí àdéhùn wà láàrin wọn |

| | | |
|---|---|---|
| | | tí oníkálùkù yóò fi mọ́ ibi tó yẹ láti rìn sí.<br>• Láti rí i dájú pé àǹfààní ìdàgbàsókè wà fún gbógbo ènìyàn olùgbe agbègbè, láìya ẹnìkan sọ́tọ̀ nípa ẹ̀yà, akọ tàbí abo, àgbà tàbí ọmọdé, abarapá tàbí aláàbọ̀ ara, olówó tàbí tálákà.<br>• Fojúsun àwọn obìnrin àti àwọn ọ̀dọ́, àwọn tí wọn ò ní àǹfàní láti fikún ọ̀nà àtijẹ wọn. |
| | **<u>Ìrìnkèrindò ọkọ̀</u>**<br>• Ìrìnkèrindò ọkọ̀ pọ̀ sí i.<br>• Ìjàǹbá mọ́tò fún ènìyàn àti ẹranko | • Ṣàfihàn gbèdéke eré tí dírẹ̀bà le sání ojú-pópó<br>• Ṣíṣe àwọn ebè sí ojú-pópó láti dín eré-sísá kù |
| | **<u>Ààbò àti Ètò Ìlera Àwùjọ àti ti Ẹnu-iṣẹ́</u>**<br>• Àìsí ìpèsè ìkìlọ̀ lórí ètò ààbò àti ìlera, àti bí wọn ṣe ń ṣàmúlò kẹ́míkà<br>• Àìsí  àti àìmọ̀ọ́lò àwọn ohun-èlò ìdáàbòbò<br>• Rírọ́wá ọ̀pọ̀ àwọn èèyàn sí agbègbè iṣẹ́, èyí tó le ṣokùnfa àìsàn bí I HIV/AIDS àti àwọn àrùn ìbálòpọ̀ mìíràn, àwọn kòkòrò àrùn, àjàkálẹ̀ àrùn àti àrùn inú omi.<br>• Ìṣòro ìrónúsí ajẹmáwùjọ | • Sètò kí o sì ṣàmúlò ọ̀rọ̀ lórí ààbò, ìlera àti àwùjọ (EHS), èyí tí yóò ṣètò ìlànà tó yẹ láti tẹ̀lé fún ìdènà ìṣẹ̀lẹ̀ àìsàn àti fún ìtọ́jú orí-eré/ojú-ẹsẹ̀/pàjáwìrì<br>• Pọn ọ́n ní dandan fún àwọn òṣìṣẹ́ láti máa dé koto ààbò sórí àti àwọn ohun mìíràn tó lè dáàbò boni ní agbègbè àkànṣe-iṣẹ́<br>• Ṣètò ìkọ́ni fún àwọn òṣìṣẹ́ nípa ọ̀rọ̀ ààbò<br>• Ṣètò ìkọ́ni fún àwọn tó ń ṣiṣẹ́ pẹ̀lú kẹ́míkà apakòkòrò, bí wọn yóò ṣe máa lo àwọn kẹ́míkà náà àti ohun tó yẹ́ ní ṣíṣe tí kẹ́míkà yí bá ṣèèṣì dànù.<br>• Ṣètò ọ̀nà àti máa tètè dá ẹni tó bá farapa lóhùn, kí àwọn |

<table>
<tr><td></td><td></td><td>àpótí oògùn àsárélò sì wà<ul><li>Ṣètò bí àwọn ará agbègbè yóò ṣe ní ìmọ̀ tó yẹ nípa àrùn HIV/AIDS àti àwọn àrùn mìíràn.</li><li>Ṣètò àyẹ̀wò ìlera</li><li>Ṣègbékalẹ̀ àgbéyẹ̀wò àwọn ewu tó máa ń fojúhàn lẹ́nú iṣẹ́ fún àwọn agbaṣẹ́ṣe, àwọn olùdarí ọ̀rọ̀-iṣẹ́, àwọn agbègbè tí ọ̀rọ̀ náà kàn.</li></ul></td></tr>
<tr><td></td><td><u>Ààbò àti Ìbójútó</u><ul><li>Ààbò àti ìbójútó àwọn tó ń ṣègbè fún àwùjọ</li><li>Ààbò àti ìbójútó àwọn tó ń ṣiṣẹ́ ní ibùdó iṣẹ́.</li></ul></td><td><ul><li>Ṣàmúlò àwọn ọdẹ agbègbè látí kún àwọn ọlọ́pàálọ́wọ́</li><li>Ṣètò ìkọ́ni lóri ọ̀rọ̀ ààbò fún àwọn òṣìṣẹ́ lóòrèkóòrè</li></ul></td></tr>
<tr><td>Ìpèsè ẹ̀gẹ́, èyí tó níí ṣe pẹ̀lú ìdọ̀tí, ìlò irin-iṣẹ́ òde-òní fún ìtọ́jú ìdọ̀tí, abbl.</td><td><u>Ìpèsè Ẹ̀gẹ́</u><ul><li>Dídọ̀tí odò</li><li>Dídọ̀tí agbègbè látàrí ìlò àwọn kẹ́míkà tí a fi ń pèsè àwọn ohun-èlò ajẹmẹ́gẹ̀ẹ́</li><li>Àwọn ìdọ̀tí àfojúrí máa ń ṣokùnfà òórùn búburú, pàápàá jùlọ láti ara ìdọ̀tí tó máa ń di adágún omi nípasẹ̀ òjò.</li><li>Ewu tó le jẹyọ látipasẹ̀ àìtètè rí kòtò àti gegele.</li><li>Eruku tó ń ti ibi tí wọ́n ti ń lọ nǹkan jáde.</li></ul></td><td><ul><li>Kí àwọn ohun-èlò iṣẹ́ jẹ́ kíkó kúrò ní ibi tí àwọn èrò pọ̀ sí àti ibi tí omi mímu wà.</li><li>Dènà aáwọ̀ làarin àwọn tó ń lò ó tàbí kí àwọn tó ń lo orísun omi náà má pọ̀ lápọ̀jù.</li><li>Ṣètò ìlànà ìtọ́jú</li><li>Dènà dída ìdọ̀tí sínú omi kí ètò láti kó ìdọ̀tí inú omi dànù sí wà</li><li>Rí i dájú pé à ń kó ìdọ̀tí síbi tó yẹ</li><li>Kí àwọn ìdọ̀tí tó jẹ́ àrídìmú má ṣe pẹ́ nílẹ̀ rárá, kí ọ̀nà láti máa ṣan àwọn ìdọ̀tí ẹ̀gẹ́ dànù sì wà.</li><li>Kí á lo ọ̀nà ìgbàlódé láti yọ ìdọ̀tí pàǹtí àtí ìgò dànù.</li><li>Kí ibùdó tí wọ́n ti ń lo ẹ̀gẹ́ jìnà sí ibi tí àwọn èrò pọ̀ sí.</li><li>Rí i dájú pé àwọn òṣìṣẹ́ lo</li></ul></td></tr>
</table>

| | | |
|---|---|---|
| | | ohun-èlò PPE láti dáàbò bo àwọ̀ ara wọn lọ́wọ́ eruku búburú tó le fa àìsàn àwọ̀, àti èyí téèyàn le fà símú. |

| Àtẹ ES b: Ìsọníṣókí àwọn ipa àti ìlànà tí a lè gbà dènà ìfàsẹ́yìn fún àwọn ìdàgbàsókè àti ìlò àwọn ohun amáyédẹrùn SZPZ àti ABIR | | |
|---|---|---|
| **Àwọn ohun tí a ní lérò láti ṣe** | **Àwọn ohun tí ó jẹ́ gẹ́gẹ́ bí ipa/tí ó mú wa lọ́kàn**. | **Ohun tí a gbèrò láti fi dènàìfàsẹ́yìn** |
| Ìdàgbàsókè ọ̀nà ìgbàgbé-afẹ́fẹ́, ti wáyà tí wọ́n fi n fa iná, ọ̀nà ìgbàpèsè omi, ọ̀nà tó dára, abbl. Gbogbo ẹ ló ní àwọn ìṣe tó papọ̀ yìí:<br><br>Ìtọ́jú ibùdó iṣẹ́ àti/tàbí ìdọ́gba-ọ̀nà, fífọ́ àwọn ohun tó yẹ. Ìlò àwọn irin-iṣẹ́ ńlá-ńlá, ohun-èlò tó léwu, wíwa àwọn nǹkan jáde láti abẹ́ ilẹ̀, òkuta-fífọ́, dída àwọn ìdọ̀ti nù àti ìtọ́jú | <u>Àyíká</u> | **C.** |
| | **<u>Àwọn Ohun-Èlò Adánidá</u>**<br><br>Ìtọ́jú ibùdó iṣẹ́ àti/tàbí ìdọ́gba ọ̀nà nípa<br><br>• Ewu tó ń fà sí àwọn ohun-èlò ajẹmáwùjọ (ìyàtọ̀ tó dé bá àwọn ewéko àti ènìyàn àti ẹranko)<br>• Ìmójútó àwọn yẹ̀ẹ̀pẹ̀ tó le fa kí omi máa wọ́ yẹ̀ẹ̀pẹ̀ lọ, ìyípadà tó dé bá ìṣàn omi àti ìbàjẹ́ sí àyíká.<br>• Àwọn nǹkan abẹ̀mí tó ti fẹ́ lọ sí òkun-ìgbàgbé (ewéko àti ẹranko) | • Ní ìṣètò ojú-ọ̀nà, o níí ṣe pẹ̀lú àwọn tó ní ìmọ̀ nípa ọ̀pọ̀ nǹkan bí i àwọn oníṣẹ́ àyíká, àwọn onímọ̀-ẹ̀rọ lórí ìmọ̀ àyíká, àwọn onímọ̀ nípa yẹ̀ẹ̀pẹ̀, nípa afẹ́fẹ́ àti àwọn mìíràn bí i òwúlẹ̀wútàn tàbí onímọ̀ nípa ìrìn-àjò afẹ́.<br>• Kí a má ṣe ṣe yẹ̀ẹ̀pẹ̀ tó dára fún nǹkan-ọ̀gbìn nísẹ̀kúṣe<br>• Má ṣe lo àwọn ilẹ̀ tó wà níbi tó léwu tàbí tí àwọn nǹkan agbègbè le pa lára;<br>• Rí i dájú pé o ya ibi kan sọ́tọ̀, bí i kìlómítà kan láàrin igbó tí o ti fẹ́ ṣiṣẹ́, níbi tí o kò níí lò fún iṣẹ́ rárá lábẹ́ SCPZ/ABIR.<br>• Mọ àwọn nǹkan tó dàbí ẹni pé wọ́n ti fẹ́ lọ sí òkun-ìgbàgbé. |

| | | |
|---|---|---|
| àwọnohun tó yẹ ní títọ́jú, kíkọ́ ilégbèé fún àwọn òṣìṣẹ́ níbùdó iṣẹ́ àti ilẹ̀-gbígbà. | **<u>Àwọn Àlùmọ́nì inú omi àti kíkọ́ ojú-odò</u>**<br><br>• Dídàámú omi tó ń ṣàn<br>• Ṣíṣan yẹ̀ẹ̀pẹ̀ sínú ojú-odò tí a ò bò<br>• Dídènà omi abẹ́ẹ̀lẹ̀ tàbí omí tí à ń fọ́n sí irè-oko. | • Fàyè tó tó nǹkan bíi igba mítà sílẹ̀ ní etí-odò láti lè dáàbò bo àwọn ẹ̀dá inú omi. Ibi tí a yà sọ́tọ̀ yí a tún dàbí asẹ́ tí yóò máa sẹ́ àwọn pàǹtí tó ń bọ̀ láti orí ilẹ̀, yàtọ̀ sí èyí, á á tún dúró gẹ́gẹ́ bí i ohun tí yóò máa dènà yẹ̀ẹ̀pẹ̀ tí omi ń ṣàn láti orí ilẹ̀.<br>• Tí kò bá ṣeé ṣe kí á gé ibi tí ó rí gẹ̀rẹ́gẹ̀rẹ́, a ó ṣe nǹkan bí ọgbà tó le ṣàtìlẹyìn.<br>• Dín gígé ibi gẹ̀rẹ́gẹ̀rẹ́ kù<br>• Ṣọ́ra fún dída ìdọ̀tí, epo rọ̀bì, sánmọ́ńtì àti àwọn ohun-èlò mìíràn sí ibi tí kò yẹ<br>• Ṣàmúlò àwọn ohun-èlò tí wọ́n fi ń dí kòtò tàbí àwọn páípù omi láti fi jẹ́ kí omi abẹ́ẹ̀lẹ̀ máa ṣàn<br>• Ṣàgbéyẹ̀wò ipa omi ní ibùdó iṣẹ́ kí iṣẹ́-àkànṣe tó bẹ̀rẹ̀.<br>• Rí i dájú pé o pèsè kòtò ìdami gẹ́gẹ́ bó ṣe yẹ fún agbègbè tí àkànṣe-iṣẹ́ náà wà.<br>• Ṣèfilọ́lẹ̀ kòtò ìdami nígbà tí iṣẹ́ ọ̀nà-ṣíṣe bá ń lọ lọ́wọ́; èyí kò níí jẹ́ kí àgbàrá wọ́ àwọn yẹ̀ẹ̀pẹ̀ lọ<br>• Ìtúndásílẹ̀ ibùdó ìfọ́kùúta nítorí tí a bá nílò a ti kọ́ ibùdó ìfọ́kùúta titun.<br>• A ó rí i dájú pé àwọn páípù tí a lò jẹ́ dídè dáadáa kí wọ́n má bá a jò. |

| | | |
|---|---|---|
| | | • Fífa omi láti inú ilẹ̀ pẹ̀lú àṣẹ láti ọwọ́ àwọn ará ìlú níbi tí òwọ̀n omi bá wà.<br>• Kí iṣẹ́ ìkọ́lé dá lórí bí omi ṣe wà sí. |
| | **<u>Ìmúdúró yẹ̀ẹ̀pẹ̀/Ìṣe ìwa-nǹkan, nǹkan gígé àti kòtò-dídi</u>**<br>• Ilẹ̀ lílà tàbí àwọn nǹkan mìíràn tó le múṣòro wá<br>• Ìṣokùnfà kí àgbàrá máa wọ́ yẹ̀ẹ̀pẹ̀ lọ<br>• Fífà àwọn ibi pàtàkì tí kò dúró ṣinṣin<br>• Tí a bá kó àwọn yẹ̀ẹ̀pẹ̀ tí a wà jáde láti inú ilẹ̀ jọ, tí àgbàrá sì ṣàn án sínú omi, ó le fa ikú àti ìṣòro fún àwọn ẹ̀dá inú omi<br>• Ó le ba àwọn ohun tó jẹ́ bí ẹ̀dá àwùjọ, àtèyí tó ń mí, àtèyí tí kò mí jẹ́ tí a bá kó àwọn ohun tí a le fi dí kòtò sí ojú àgbàrá<br>• Ewu tó wà fún àwọn | • Ìdáàbòbò àwọn ilẹ̀ tó wà lórí òkè kí wọ́n má báa gé dànù<br>• Ìdáàbòbò àwọn ilẹ̀ tó wà ní ìpẹ̀tẹ́lẹ̀ lọ́wọ́ ìdọ̀tí àti pàǹti láti iṣẹ́ ilé-kíkọ́<br>• Gbígbẹ́ kòtò ìdami láti le dènà kí àgbàrá máa wọ́ yẹ̀ẹ̀pẹ̀ kúrò.<br>• Ẹ̀kọ́ nípa àyíká láti lè mọ̀ ọ̀nà tó dára jùlọ láti lò.<br>• Lílo àwọn ohun tí àwọn onímọ̀ ẹ̀rọ lórí kíkọ́ ohun amáyédẹrùn àwùjọ kọ́<br>• Kí á dènà gígé tí àwọn ilẹ̀ tó wà ní gẹ̀rẹ́gẹ̀ré máa ń gé<br>• Kí a rí i pé ọ̀nà ẹ̀gbẹ́ orí-òkè kò yọ̀ láyọ̀jù<br>• Kí á dènà òkuta-fífọ́ ní àwọn etídò níbi tí àgbàrá ti le tètè wọ́ òkuta sínú omi.<br>• Rí i dájú pé àwọn òṣìṣẹ́ ń |

| | | |
|---|---|---|
| | òṣìṣẹ́ tó ń ṣiṣẹ́ ní ibi tí a ti ń wa nǹkan. | tẹlé òfin ààbò, kí wọ́n sì máa lo àwọn ohun tó le dáàbò bò wọ́n nígbà tí nǹkan bí òkuta àti àpáta bá ń fò kiri. |
| | **<u>Afẹ́fẹ́ àti Ariwo</u>**<br>• Ìdínkù afẹ́fẹ́ gidi nítorí ìrìnkèrindò ọkọ̀ tí o ń gbé irin-iṣẹ́ sókè-sódò, àwọn iṣẹ́ tó rọ̀ mọ́ ilé-kíkọ́ tàbí ilẹ̀-wíwà<br>• Ìjàǹbà tó le ṣẹlẹ̀ nínú afẹ́fẹ́ nípa sísun àwọn igbó tí a ti gé kalẹ̀. | • Kí á fi omi wọ́n ilẹ̀ kí a tó fi ọkọ̀ onírin kì í mọ́lẹ̀ látile jẹ́ kí ilẹ̀ náà ní okun bí bẹ́ẹ̀ kọ́, ìrìkèrindò ọkọ̀ kò níí pẹ́ ba ọ̀nà náà jẹ́<br>• Bí ó bá ṣeé ṣe, kí á dá lílo ọkọ̀ onírin láti ki ilẹ̀ dúró títí di ìgbà tí òjò fẹ́ bẹ̀rẹ̀ tàbí nígbà tí omi bá pọ̀ dáadáa.<br>• Ó yẹ ká rí i dájú pé à ń ṣàyẹ̀wò sí àwọn ọkọ̀ àti àwọn irin-iṣẹ́ mìíràn láti dín ewu tó wà nínú èèfín tó ń jáde nínú wọn kù.<br>• Ìdánilẹ́kọ̀ọ́ ṣíṣe fún àwọn awakọ̀ láti má ṣe sáré àsápajúdé, pàápàá ní ìgbàẹ̀ẹ̀rùn.<br>• Ìdínkù sísun àwọn ohun tó le fa ewu sínú afẹ́fẹ́.<br>• Kí á dín eré-sísá kù nípa ìlò ebè sójú pópó. Tí omi bá wà, kí wọ́n máa fọ́n omí |

| | | |
|---|---|---|
| | | sí ojú pópó lóòrèkóòrè<br>• Ebè ojú-pópó tí kò níí jẹ́ fúngbà díẹ̀ ní àwọn ọ̀nà abúlé.<br>• Dída ọ̀dà sójú-pópó pẹ̀lú ebè láti dín eré-sísá kù.<br>• Ọ̀gbìn àwọn ewéko sí ẹ̀bá-ọ̀nà.<br>• Kí á ní àkókò iṣẹ́ fún oníkálùkù láti dín ìdíwọ́ kù.<br>• Kí a sọ fún àwọn ara-ìlú tí ó bá jẹ́ pé ariwo yóò pọ̀ lẹ́nu iṣẹ́. |
| | **Ìlò Àwọn Irin-iṣẹ́ Ńlá-ńlá àti Ohun-èlò tó Léwu**<br><br>• Ìṣokùnfà kí á máa pàdánù ojú-ilẹ̀ nítorí ìlò àwọn irin-iṣẹ́ ńlá-ńlá, ọ̀kọ̀ akẹ́rù, àti ìjàǹbá tó wà fún etídò<br>• Ilẹ̀ tí a ti fi ọkọ̀-irin kì yóò ti yí ojú padà, kò sì níí dará fún iṣẹ́-àgbẹ̀ mọ́ lọ́jọ iwájú<br>• Oríṣiríṣi epo mọ́tò tó bá dà sílẹ̀ le ṣe àkóbá ńla fún omi tó ń ṣàn lábẹ́ ilẹ̀.<br>• Yóò jẹ́ kí àwọn òṣìṣẹ́ wà nínú ewu ńlá<br>• Ewu tún wà nínú àwọn ohun-èlò tí a fí ń ṣe ọ̀nà bíi ọ̀dà àti àwọn ohun-èlò mìíràn<br>• Àìlo àwọn ohun-èlò iṣẹ́ lọ́nà tó yẹ, léyìí tó | • Ìmójútó àwọn irin-iṣẹ́ àti àwọn ohun-èlò mìíràn<br>• Díndín ìlò irin-iṣẹ́ ńlá-ńlá kù<br>• Fífi òfin lélẹ̀ nípa ìlò àwọn irin-iṣẹ́ àti ọkọ̀ bí pé kí wọ́n máa rọ epò sínú wọn ní ibùdó-iṣẹ́, kí wọ́n máa tún wọn ṣe ní ibi tí epo ti lè dá sílẹ̀ tàbí kí wọ́n tẹ́ ọ̀rá sílẹ̀ kí wọ́n tó ṣe àwọn nǹkan wọ̀nyí. Dídáná sun àwọn epo mọ́tò tí kò wúlò mọ́. Kí a má sì gbà kí wọ́n máa fi irú èpo bẹ́ẹ̀ dáná oúnjẹ.<br>• Kí a ṣe ìwádìí lórí ìlò àwọn ohun-èlò mìíràn tí nǹkan tí wọ́n fi ṣe é kò lágbára jù.<br>• Dènà jíjò táǹkì epò mọ́tò nípa a)kí a máa ṣàkíyèsí bí epo ṣe kúntó nínú táǹkì, b) ṣíṣe àyẹ̀wò àwọn páìpù epo dáadáa, d) dídé ilé- |

| | | |
|---|---|---|
| | le fa ewu fún àwọn oṣìṣẹ́.<br>• Àdánù tó máa ń ṣẹlẹ̀ sí àwọn ohun-èlò iṣẹ́.<br>• Ó ṣeé ṣe kí àwọn ohun-èlò dànù nígbà tí a bá ń kó wọn lọ dànù lórí oko. | epo èrọ amúnáwá le, e) kí á má ṣe rọ èpò sínú àwọn táǹkì náà kún jù.<br>• Kí a dènà ìfohun-èlò ṣòfò nípa kí ilẹ̀ má rí gbágun-gbàgun. Kí a ya ibi tí kò léwu sọ́tọ̀ níbùdó iṣẹ́.<br>• Owó gbà-má-bìínú fún àwọn tó nílẹ̀<br>• Ṣàyẹ̀wò látí rí i pé ibi ìkóǹkansí dára láti dín àdánù kù.<br>• Ṣàyẹ̀wò láti rí i pé òṣìṣẹ́ ń wọ àwọn aṣọ tó le dín ewu kù. |
| | **<u>Ìbójútó Ìdọ̀tí</u>**<br><br>• Ìtọ́jú àwọn ìdọ̀tí lọ́nà tó yẹ lẹ́nu iṣẹ́. | • Ṣètò ìlànà láti máa da àwọn ìdọ̀tí nù lọ́nà tó yẹ nílànà pẹ̀lú àkọ́ọ́lẹ̀ nípa ọ̀rọ̀ ìtọ́jú ìdọ̀tí<br>• Kí á fi àyè gba láti máa tún àwọn nǹkan mìí tó ṣeé lò lò, èyí tún le dín ìdọ̀tí tí a fẹ́ dànù kù. |
| | AJẸMÁWÙJỌ | |

| | | |
|---|---|---|
| | **<u>Ìlò Ilẹ̀/Ilẹ̀  Gbígbà</u>**<br><br>• Kíkúrò lórí ilẹ̀, èyí tó le (i) ṣàkóbá fún ẹni tó ń ṣe iṣẹ́-òòjọ́ lẹ́bàá ọ̀nà; tàbí (ii) nítorí ọ̀rọ̀ ààbò, àwọn ohun-èlò iṣẹ́ máa ń wà ní ibòmíràn, léyìí tó le fà ìnira fún àwọn tó ń gbé agbègbè yí. | • Ní àpérò pẹ̀lú ilé-iṣẹ́ ìjọba tó ńrí sí ọ̀rọ̀ ilẹ̀ láti ran àwọn àgbẹ̀ lọ́wọ́ láti ya ilẹ̀-oko wọ́n sọ́tọ̀ àti láti ní àkọọ́lẹ fún ọjọ́ iwájú.<br>• Ètò tó yẹ ní ṣíṣe lórí ilẹ̀ tí yóò jẹ́ ìtẹ̀wọ́gbà fún ìlò lọ́jọ́ iwájú<br>• Fi àyè gba ìjíròrò pẹ̀lú àwọn tí ọ̀rọ̀ kàn láti le mọ ìṣe tó yẹ ní lílò, pẹ̀lú àjọṣepọ̀ pẹ̀lú àwọn ará ìlú.<br>• Ìfílọ̀lẹ̀ ẹ̀tọ́ àwọn àgbẹ̀ láti kópa nínú ìjíròrò lórí yíya ilẹ̀ sọ́tọ̀ fún ABIR. Àti iye tí yóò jẹ́. |

| | | |
|---|---|---|
| | **<u>Ilé Kíkọ́ – ìbùgbé abọ́dé àti àwọn òṣìṣẹ́</u>**<br>• Bíba ibùgbé àwọn ohun abẹ̀mí gbogbo jẹ́, ìfúnmọ́ra àwọn iyẹ̀pẹ̀ àti fífí àyè gba àgbàrá nípa ṣíṣe iṣẹ́ ìkọ́lé<br>• Mímú ìdọ̀tí àrídìmú wọnú odò láti ara ìdòtí àti ìgbọ̀nsẹ̀ tí ó lè mú àjàkálẹ̀ àrùn wá bíi ibà, ikọ́ efée àti àrùn éèdì láti ara àwọn òṣìṣẹ́ tí ó wá láti agbègbè mìíràn<br>• Gbígbé ìdáṣà ọtí mímú tàbí àwọn ìwà àidáa mìíràn wá láti ọ̀dọ̀ àwọn òṣìṣẹ́ ìkọ́lé<br>• Àwọn òṣìṣẹ́ ìkọ́lé lè mú ìpalára bá àwọn ohun abẹ̀mí àyíká nípa pípa àwọn ẹranko fún jíjẹ àti lílo àwọn igi fún ìdáná<br>• Mímú kí pàntí pọ̀ káàkiri nítorí àìsí ètò fún ìsọlọ́jọ wọn | • Kíkọ́ ìbùgbé abọ́dé fún àwọn òṣìṣẹ́ ìkọ́lé sí àwọn agbègbè tí ó yẹ<br>• Pípèsèàwọn ohun èlò ìkọ́lé tó yẹ fún àwọn òṣìṣẹ́.<br>• Ìpèsè ìkọ́ni tó péye fún àwọn òṣìṣẹ́ nípa bí a ti ń hùwà láwùjọ àti ìkéde nípa àrùn Éèdì àti irú àwọn àrùn àkóranni bẹ́ẹ̀<br>• Pípàṣẹ fún àwọn òṣìṣẹ́ láti má máa pa àwọn ẹran ìgbẹ́ mọ́<br>• Ṣíṣe ètò ìpalẹmọ́ tó péye |
| | **<u>Mímú ìdàrú bá àwọn ohun àmúlò</u>**<br>• Mímú àtúntò bá àwọn ohun àmúlò<br>• Mímú ìsúnkẹrẹ-fà-kẹrẹ ọkọ̀ pọ̀ síi àti dídín ìrìnnà ọkọ̀ kù láyìíká | • Fífi tó àwọn ará ìlú àti àwọn tó ń lò wọ́n létí<br>• Àtúnkọ́ àwọn ohun àmúlò sí agbègbè mìíràn<br>• Rírí dájú pé àwọn àmì atọ́kọ̀sọ́nà wà pẹ̀lú èyí tí kò fàyè gba eré àsápajúdé ọkọ̀ ní àwọn agbègbè kan<br>• Pípèsè àwọn ọ̀nà ẹlẹ́sẹ̀ ní àwọn agbègbè tí àwọn èèyàn ń gbé láàárín àwùjọ. |
| | **<u>Ìdènà ewu àti ètò àbò</u>**<br>• Àwọn alamín àti olófòófó lórí ọ̀rọ̀ ìdènà-ewu àti ètò ààbò | • Ṣíṣe àgbékalẹ̀ òfin àti ètò ìdáàbò bo àwọn àgbẹ̀ àti àwọn òṣìṣẹ́<br>• Pípèsè àwọn àmì ìdènà |

| | | |
|---|---|---|
| | • Ètò ìdènà ewu àti ìdáàbò bo àwọn òṣìṣẹ́ níbi iṣẹ́ wọn<br>• Eré àsápajúdé àwọn awakọ̀ tó lè ṣe ìjàǹbá fún àwọn ènìyàn àti àwọn ẹranko<br>• Lílo àwọn ẹ̀rọ iṣẹ́ máa ń mú ìpalára bá àwọn amojú-ẹ̀rọ àti àwọn òṣìṣẹ́<br>• Àwọn ihò tí a kò gbèrò tó yẹ lé lórí kí a tó gbẹ́ àti àwọn kùsà tí a wà tí omi sì ti kún inú rẹ̀ lè ṣe ìjàǹbá fún àwọn ènìyàn | ewu àti àwọn ohun ìtanilólobó nípa ààbò sí àwọn ọ̀nà páìpù<br>• Ìpèsè ìkọ́ni fún àwọn amojú-ẹ̀rọ àti àwọn òṣìṣẹ́ nípa àwọn ọ̀nà ti à ń gbà lo àwọn ẹ̀rọ wọ̀nyí bí ó ti yẹ<br>• Àwọn ihò kùsà yóò jìnnà sí àwọn ọ̀nà ibi iṣẹ́. |
| | **<u>Ètò ìlera àti ìdèna ewu àwùjọ àti ti àwọn òṣìṣẹ́ lẹ́nu iṣẹ́</u>**<br>• Àwọn òṣìṣẹ́ ojú ọ̀nà lè fara kó oríṣi àìsàn, ní pàtàkì àrùn HIV/Éèdì àti àwọn àrùn ìbálòpọ̀ mîìràn, wá bá àwọn ará agbègbè<br>• Ìjàǹbá láti ara àwọn irin iṣẹ́<br>• Àwọn ìjàm̀bá tí ó ṣẹlẹ̀ nítorí àìṣètò ibi iṣẹ́ dáadáa<br>• Àìtó àwọn ohun èlò àdàni àti lílò wọ́n lọ́nà àìtọ́/àìsí òfin ìlò àwọn nǹkan èlò wọ̀nyí<br>• Ìbúgbàmù/jíjo gáàsì nínú páìpù | • Àgbékalẹ̀ ètò àti ìlànà ìpolon̄go láti kọ́ àwọn ènìyàn nípa ìdáàbò bò ètò ìlera àwọn òṣìṣẹ́ àti ìtójú àwọn kẹ́míkà . Iṣẹ́ náà yóò nílò àbá tó jẹ mọ́ ìdènà ewu, àyíka àti ìlèra tí yóò tọ́ka sí àwọn ìlànà ìdẹ́kun ewu ajẹmọ́lera lẹ́nu iṣẹ́<br>• Ìpolongo nípa àrùn HIV/Éèdì<br>• Ìgbékalẹ̀ ìlànà ìdáhùnsí onípàjáwìrì tí ó ní ìpèsè àpótí oògùn ìtọ́jú oníkánmọ́kánmọ́ nínú<br>• Ìpèsè ìlànà ìdáhùnsí onípàjáwìrì fún ìjàǹbá iná láti ara bíba àwọn páípù gáàsì jẹ́, ìdúngbàmù abbl.<br>• Kíkàn nípa fún àwọn òṣìṣẹ́ láti máa wọ àwọ̀n/ibòjú<br>• Ìpèsè ẹ̀kọ́ nípa àwọn ìlànà ìtọ́jú tó jẹ́ mọ́ iṣẹ́ ohun èlò àdáni adáàbò boni (PPE) bí ó ti yẹlọ́nà tí yóò dẹ́kun ìfarapa lẹ́nu iṣẹ́. Ríri i dájú |

| | | |
|---|---|---|
| | | pé àwọn òṣìṣẹ́ ṣàmúlò PPE bó ti yẹ<br>• Ìpèsè àwọn àmì ìdènà ìjàǹbá ọkọ̀ lójú pópó<br>• Ìpolongo ìdènà ìjàǹbá lójú pópó láàárín àwọn agbègbè tí ọ̀rọ̀ kàn<br>• Ṣíṣe àyẹ̀wò àwọn ìlànà ìdènà ewu ojú pópó pẹ̀lú fífi àwọn àbá ìlọsíwájú ṣiṣẹ́ ṣe. |
| | **<u>Àṣà Àjogúnba</u>**<br>• Bíbẹ̀gidínà àṣà àti idúróṣinṣin àwùjọ nípa:<br>• Ìyípadà àwùjọ onípàjáwìrì tàbi ipa àwọn arìnrìn-àjò abẹ̀lúwò<br>• Itẹ́kùú àti àwọn agbègbè àdàsí ajẹmẹ́sìn<br>• Nípa ìwúlẹ̀ a le ṣalábàápàdé àwọn nǹkan ìṣúra fún àwọn awúlẹ̀wútàn tàbí àwọn ohun ajẹmáṣà mìíràn tí ó lè ti bàjẹ́ ní agbegbè ìkọ́lé yìí | • Ìdẹ́kuṅ líla ọ̀nà iṣẹ́ gba àwọn ibi tí a ti yà sótọ̀ tó jẹ́ mọ́ ìkẹ́kọ̀ọ́ nípa àṣà àwùjọ, ìwúlẹ̀wútàn tàbí ẹ̀sìn<br>• A ó dá àwọn ojúbọ àti àwọn ìgbàlẹ̀ sí tí a bá ń ṣán igbó fún ìdàgbàsókè àyíká<br>• Ṣíṣe àwọn ètùtù tó yẹ ká tó wọ àwọn agbègbè tí ìgbàlẹ̀ wà<br>• Yíyàgò fún ìkọlura tó jẹ mọ́ iṣẹ́<br>• Ìdáàbò bò àwọn ààlà lọ́wọ́ ìkọlura nítorí ìkọ́lé<br>• Ìṣíkúrò nítorí ìkọlura ò ṣeé sá fún<br>• Ìpèsè ìlànà tó yè kooro fún ìtọ́jú àwọn ohun ajẹmọ́-ìwúlẹ̀wútàn tí a ṣàdéédé rí nínú ilẹ̀ ní ìbámu pẹ̀lú ètò Ohun Amúlò Àfojúrí Ajẹmáṣà (OP/BP 4.11) |
| | **<u>Rúkèrúdò Àwùjọ</u>**<br>• Tí àwọn ara agbègbè ò bá kópa nínú iṣẹ́ | • Ṣíṣe àgbékalẹ̀ ìlànà àmúṣẹ́ṣe tí ó lè pèsè iṣẹ́ fún àwọn ará agbègbè náà |

| | | |
|---|---|---|
| | • Àìmúlérí tí a ṣe fún àwọn ará ìlú ní àkókò ìpìlẹ̀ iṣẹ́ ṣẹ<br>• Àwọn tí wọ́n ń da ẹran kiri á pàdánù oko ìjẹ fún ẹran wọn | • Rírii dájú pé àwọn agbaṣẹ́ṣe lo àwọn òṣìṣẹ́ àwùjọ lóòrèkóòrè<br>• Rírii dájú pé ìlérí fún àwọn ará àwùjọ di ìmúṣẹ; tí wọn ò bá ṣeéṣe kí ṣe àtúngbéyẹ̀wò wọn<br>• Wíwá ilẹ̀ mìíràn fún àwọn adaran kí àwọn ẹran wọn lè máa rí nǹkan jẹ |
| | **<u>Ìtọ́jú àwọn ohun èlò</u>**<br>• Àwọn ohun èlò tí kò ṣiṣẹ́ déédé mọ́ | • Ṣíṣe ìtọ́jú àti amójútó àwọn ìlànà àti ètò gbogbo<br>• Ìbójútó iṣẹ́ àwọn agbaṣẹ́ṣẹ pẹ̀lú ìjìyà tó tọ́ fún àìṣe iṣẹ́ bó ti yẹ<br>• Gbígbé ìgbésẹ̀ tó yẹ kí àwọn páìpù onírin má bàá dípẹtà |

***Àbẹ̀wò Ààrọ̀ Ìṣẹ́ 'Kò Síṣẹ́' àti ' Tẹ̀ Síwájú'***

Àtúpalẹ̀ àwọn iṣẹ́ ààró jẹ́ ìlànà àgbéyẹ̀wò ọlọ́pọ̀ ìlànà tí à ń lò láti ọjọ́ pípẹ́ fún ètò ìgbéléwọ̀n àwùjọ.Ìdí àtúpalẹ̀ àwọn ààrọ̀ iṣẹ́ yìí ni láti mọ̀ èyí tí ó kúnjúwọ̀n jù fún ìdàgbàsókè àwùjọ déédé. Àwọn iṣẹ́ ààrọ̀ yìí ni a gbéyẹ̀wò ní ìbámu pẹ̀lú iṣẹ́ tí a fẹ́ ṣe.

A máa ń ṣẹ àtúpalẹ̀ àwọn awọn ààrọ̀ iṣẹ́ wọ̀nyí ki a lè fìdí àfojúsùn iṣẹ́ tó pé àwùjọ, tí owó rẹ̀ ò sì pọ̀ jù múlẹ̀. Èyí wà lọ́wọ ìfiwére ìlapa ìdókòwò ní ibi iṣẹ́, ìmọ̀-ẹ̀rọ, ìmúṣẹ́ṣe abbl pẹ̀lúipa àti àwòjinlẹ̀ ìmúdínkù, owó-ìná, owó ajẹyọ-látigbàdégbà, yíyẹ ní àyè pẹ̀lú ìlàna tí a fẹ́, ètò ìkọ́ni àti ètò àbójútó. Fún ààrọ̀ kọ̀ọ̀kan, a gbọ́dọ̀ ṣàgbéyẹ̀wò ipa rẹ̀ lórí àwùjọ débi ríronú nípa èrè ètò ọrọ̀-ajé ní àwọn ibi tó yẹ léyìí tó jẹ́ ìdí pàtàkì tí a ó fi mú ààrọ̀ iṣẹ́ tí a bá fẹ́.Oyẹ kí àtúpalẹ̀ ààrọ̀ iṣẹ́ ní èyí tí a mọ̀ sí 'KÒ SÍ ÀMÚṢE'.

Àwọn ààrọ̀ wọ̀nyí ni a gbà lérò fún àwọn agbègbè iṣẹ́ –

Ààrọ̀ 'Kò sí Àmúṣẹ́' jẹ́ èyí yóò rii dájú pé a kò fi ọwọ́ kan àwọn agbègbè tó ti wà tẹ́lẹ̀. Èyí túmọ̀ sí pé a ó fi àwọn agbègbè SCPZ àti ABIRtí a ti yà sọ́tọ̀ fún ìmúṣẹ́ṣe sílẹ̀ ní ipò tí wọ́ṅ wà tẹ́lẹ̀ léyìí tí ó sì lè mú kí wọ́n máa bàjẹ́ ju ti tẹ́lẹ̀ lọ. Ní pàtàkì, tí a bá fi

irú àgbègbè yìí sílẹ̀ láì mú dàgbàsókè wá, iṣẹ́ ọ̀gbìn ò ní tán lórí ilẹ̀ yìí léyìí tí ó lè fa ìpalára fún ibùgbé àwọn ohun abẹ̀mí agbègbè náà nígbà tí àgbàrá, igi gígé abbl bá tẹ̀ síwájú. Lọ́nà mìíràn ìpalára yìí lè tún tẹ̀ síwájú ní àwọn aginjù tó kù nígbà tí àwọn àjọ alámòójútó ò bá ṣe àmójútó tàbi tọ́jú wọn bó ti yẹ. Síwájú síi, àìlówó àwọn ará agbègbè yìí a pọ̀ síi léyì tí yóò bẹ́gi dínà àfojúsùn ètò Ìjọba Àpapọ̀ ATA.

*A kò fọwọ́ sí ṣíṣe àmúlò àwọn ààrọ̀ 'Kò sí Àmúṣe' àti 'Kò sí Iṣẹ́'*

**Ààrọ̀'Iṣẹ́ Tẹ̀ Síwájú'**, bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé ó wọ́n nípa ìnáwó ní gbogbo ọ̀nà ní ìbẹ̀rẹ̀, a rí i gẹ́gẹ́ bí èyí tí ó ṣeéṣe ju ààrọ̀ 'Má ṣe nǹkankan' lọ. Ààrọ̀ 'iṣẹ́ tẹ̀ síwájú' ni a gbèrò pé ó lè mú ẹ̀dínkù bá ìṣẹ́ ìpèsè ẹ̀gẹ́ lọ́nà ìdá ọgbọ̀n nínú ọgọ́rùn-ún tí yóò pèsè iṣẹ́ tó tó 7,500 tí yóò sì tún mú àlékún bá ọrọ̀ ajé Nàìjíríà lọ́nà tó tó US$ 0.5b. Ìdàgbàsókè AIR/SCPZ ti Alape yóò fi agbára fún ìpèsè oúnjẹ, yóò mú ìdàgbàsókè bá ètò ọrọ̀-ajé ìgbèríko, yóò sì mú ìgbé-ayé àwọn olùgbé agbègbè náà rọrùn nípa owó tí yóò máa wọlé nípasẹ̀ ìfà ọjà títà, ìpèsè ohun títà lọ́pọ̀ yañturu, ẹ̀dínkù tí yóò ti dé bá ìpàdánù àwọn irè-oko lẹ́yìn ìkórè, ìpèsè iṣẹ́ fárá ìlú lọ́pọ̀ yanturu. Ní àfikún, ìdínkù yóò bá ipa òdì tó ń bá àwùjọ fínra láti ọwọ́ àwọn àgbẹ̀ tí wọ́n ń bá àyíká jẹ́ lọ́nà àti wá oúnjẹ òòjọ́ wọn. Ó sì lè kásẹ̀ kúrò nílẹ̀ pátápátá nítorí pé,nípasẹ̀ iṣẹ́ yìí, a ó pèsè ìmọ̀ tó péye nípa àwùjọ àti bí a ṣe lè ṣètọ́jú àwọn ohun àlùmọ́nì àwùjọ. Èyí yóò dín àìrówóná kù ní àwọn agbègbè wọ̀nyí.

Àwọn àṣedánwò méjì tí a gbà lérò ni a yán léréfèé sí Àtẹ ES c. Ohun tí à ń tọ́ka sí níbi ni pé bó tilẹ̀ jẹ́ pé ààrọ̀ 'iṣẹ́ tẹ̀ síwájú' yìí fẹnú, òun ló yẹ láwùjọ jù tí owó-ìná rẹ̀ sì mọ níwọ̀nba láti lè ríi dájú pé iṣẹ́ náà di ṣíṣelọ́nà tí yóò fa ìmúgbòòrò ètò ọrọ̀-ajé àwùjọ àti ìdàgbàsókè àwùjọ déédé ní gbogbo ọ̀nà.

Fún ìdí èyí, àwọn àǹfàání 'tẹ̀ síwájú' mú un dára ju 'kò sí àmúṣe' lọ.

| **Àtẹ ES c. fún Àtúpalẹ̀ Àwọn Ààrọ̀** | | |
|---|---|---|
| Òṣùwọ̀n | Ààrọ̀ 'Kò sí Iṣẹ́' | Ààrọ̀ 'Tẹ̀ Síwájú' |
| Ìdáàbò bo àwùjọ àti ẹ̀mí ìbágbépọ̀ àníkárí | Nígbà tí a lọ sí àwọn agbègbè wọ̀nyí, a mọ̀ nípa bí àwọn ohun àmúlò àwùjọṣe ń bàjẹ́ síi lójoojúmọ́ tó fi jẹ́ pé tí a bá mú ààrọ̀ 'kò sí àmúṣe' kò níí pé àwọn ará agbègbè náà tàbí agbègbè wọn àti pàápàá ètò ọrọ̀-ajé orílẹ̀-èdè ní àkókò yìí tí ìjọba ti ń ṣí ọkàn kúrò lára ọrọ̀-ajé ajẹmépo rọ̀bì sí èyí tí kò jẹ mọ́ epo rọ̀bì | Ìdásí yìí yóò já sí fífí agbára fún ìdàgbàsókè ètò ọ̀gbìn yóò sì fi àyè gba ìtọ́jú ilẹ̀ àti àwọn ohun àlùmọ́nì gbogbo. Yóò mú owó wọlé léyìí tí yóò ran igbé-ayé àwọn ará agbègbè náà lọ́wọ́; bákan náà ni yóò sì bù kún ètò ọrọ̀-ajé orílẹ̀-èdè bí kò tilẹ̀ sí òwò ajẹmépo rọ̀bì |
| Ìwúlò Ọlọ́jọ́ Pípẹ́ | Ààrọ̀ 'kò sí àmúṣe' ò kúnjúwọ̀n fún ìwúlò | Ààrọ̀ 'tẹ̀ síwájú' yóò bù kún |

| | | |
|---|---|---|
| àti Àìlèyípadà | ọlọ́jọ́ pípẹ́ àti àìlèyípadà ètò ọrọ̀-ajé orílẹ̀-èdè àti ti ìgbèríko, bákan náà ni kò ní ìbámu pẹ̀lú àbá ìtọ́jú àwọn ohun àmúlò àwùjọ fún ìmúdàgbàsókè onídéédé | ètò ọrọ̀-ajé orílẹ̀-èdè àti ti ìgbèríko pẹ̀lú àbá ìmúdàgbàsókè onídéédé lọ́kàn pẹ̀lú ìfètòsí tí ó gùn lé ìgbèrò tó jinná látọwọ́ gbogbo àwọn tí ọ̀rọ̀ kàn tí kò sì yọ àwọn ará àwùjọ náà sílẹ̀. |
| Títẹ̀lé àwọn ìlànà tí ó yẹ | Èyí ò ní títẹ̀lé àwọn ìlànà tí ó yẹ nínú ní gbogbo ìpele àti ìpele ti agbègbè iṣẹ́ náà pàápàá | Gbogbo ohun àdáwọ́lé ni yóò di yíyẹ̀wò fínnífínní láti ríi dáju pé a tẹ̀lé àwọn ìlànà tó yẹ lái yọ ti ìpele ti agbègbè iṣẹ́ náà sílẹ̀ |
| Ìwúlò Ọlọ́jọ́ kúkúrú | Ààrọ̀ 'kò sí àmúṣe' ò ní ohun àfikún kankan lábẹ́ òṣùwọ̀n yìí | Ààrọ̀ 'tẹ̀ sí wájú' yóò di pípari lẹ́yìn ọjọ́ pípẹ́ léyìí tí ó wà lọ́wọ́ bí a bá ti pèrò rẹ̀ tẹ̀lẹ́ àmọ́ àwọn àǹfààní àbájáde rẹ̀ ju ti 'kò sí àmúṣe' lọ tí a bá wo ọ̀nà tó fi ń dàgbà díẹ̀díẹ̀. |

### ***Ìmúṣẹ́ṣe àti Ìtọ́jú ESMF***

Àṣeyọrí ìmúṣẹ́ṣe tí ESMF gùnlé bí ó ti jẹ àwọn ipele àwùjọ àti àwọn iléeṣẹ́ tí ọ̀rọ̀ kàn lógún tó, bákan náà agbára iléeṣẹ́ náà láti dáwọ́lé iṣẹ́ náà bí ó ti yẹ pẹ̀lú àwọn ètò tí ó jẹ́ ẹ̀tọ́ fún iléeṣẹ́ náà àti àwọn nǹkan mìíràn bẹ́ẹ̀. Nítorí náà, àwọn ibi tó ṣe pàtàkì fún àṣeyọrí ESMF wà nínú àkọsílẹ̀ rẹ̀, àwọn ni: ètò iléeṣẹ́, ìfagbárafúnni, ìbójútó àwùjọ àti àyíká. Iṣẹ́ àti ìṣe àwọn ipele iléeṣẹ́ yìí nínú ESMF náà ni a tò sínú Àtẹ ES d.

| **Àtẹ ES d: Ojúṣe Ààbò** | | |
|---|---|---|
| **No.** | **Ìpele** | **Ojúṣe** |
| 1 | PMU | Ojúṣe àwọn àjọ amúṣẹ́ṣe ní láti:<br>- Tẹ̀lé ìlànà ààbò Báńkì Àgbáyé àti àwọn òfin Nàìjíríà mìíràn nínú SCPZ àti ABIR tó jẹ mọ́ ESMF yìí<br>- Ríi dájú pé ìmúṣẹ́ṣe kò ní kọ̀lọ́fín nínú<br>- Dágbá lé ìmùṣẹ́ṣe ti ESMF tó ṣeé fọkàn tán àti àwọn ohun-èlò ààbò mìíràn tí à ń lò fún àwọn iṣẹ́ kéékèèké mìíràn |

| | | |
|---|---|---|
| 2 | Abala Iṣẹ́ Ààbò PMU | - Ran PMU lọ́wọ́ láti tẹ̀lé ìlànà Báǹkì Àgbáyé fún ààbò àti àwọn òfin ilẹ̀ Nàìjíríà mìíràn.<br>- Darí ètò láti ríi dájú pé àyẹ̀wò iṣẹ́ fínnífínní fún àwọn ohun-èlò ààbò lábẹ́ SCPZ di ṣíṣe<br>- Ríi dájú pé gbogbo ìwé ààbò di yíyẹ̀wò kí ó tó kọ́ja lọ sọ́dọ̀ Báǹkì Àgbáyé<br>- Ìbójútó àwọn agbaṣẹ́ṣe, alábòójútó, ìdánilẹ́kọ̀ọ́ fún àwọn kọ̀ngílá àtì àwọn òṣìṣẹ́, ìbójútó ìmúṣẹ́ṣe lábẹ́ ESMF àti àwọn ohun èlò àbò mìịràn |
| 3 | Iléeṣẹ́ Ìjọba Àpapọ̀ Abójútó Àyíká àti àwọn ibi iṣẹ́-abánimójútó (bí NASREA) | - Olú ojúṣe – Ìpèsè àbá lórí àyẹ̀wò fínnífínní, ìfojúwò, àtúnwò àṣamọ̀ ìjábọ̀ EA/ESMP (ní ìfọwọ́rinwọ́ pẹ̀lú Iléeṣẹ́ Ìjọba Àpapọ̀ Abójútó Àyíká), gba ohun tí àwọn tí ọ̀rọ̀ kàn bá sọ sílẹ̀, ìkédè àbá lórí iṣẹ́, ṣe àgbékalẹ̀ àjọ ìpérò lórí ìmọ̀-ẹ̀rọ, ìlapa-iṣẹ́ fún EA, ríríi dájú pé iṣẹ́ kúnjúwọ̀n, ṣíṣe òfíntótó ojúṣe àyíká àti àwùjọ, ìbójútó àti ìgbéyẹ̀wò àwọn ètò àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. |
| 5 | Ẹ̀ka Iléeṣẹ́ Ìjọba Abójútó Ètò Ọ̀gbìn àti Ìdàgbàsókè Ìgbèríko (FMARD) | - Yóò dúró gẹ́gẹ́ bí adarí fún àwọn MDA tó kù nípa dída àwọn pàtàkì tí ọ̀rọ̀ kàn lóhùn nínú SCPZ àti ABIR láti ṣàtìlẹ́yìn, fọwọ́sowọ́pọ̀ àti láti darapọ̀ mọ́ ìdarí òfin ìdásílẹ̀; àti<br>- Láti ríi dájú pé àwọn olùdókòwò tẹ̀lé gbogbo òfin àti ìlànà tó rọ̀ mọ́ àyíká bó ti yẹ. |
| 6 | Ẹ̀ka Iléeṣẹ́ Ìjọba Abójútó Ètò Ọ̀gbìn ti Ìpínlẹ̀ Kogí | - Darí gbogbo ètò tó jẹ mọ́ ètò ọ̀gbìn ní gbogbo agbègbè Ìpínlẹ̀ Kogí léyì tí kò ta yọ kíké gbàjarè sí àwọn àgbẹ̀ nípa oògùn apakòkòrò tí ó wà ní ìbámu pẹ̀lú ESMF àti IPMP yìí. |
| 7 | Àjọ Ìpínlẹ̀ Abójútó Agbègbè Ìtọ́jú Nǹkan Ọ̀gbìn | A kò tíì dá èyí sílẹ̀ àmọ́ yóò dúró gẹ́gẹ́ bí ibi iṣẹ́-abánimójútó gbòógì tí Ìjọba Àpapọ̀ ní gbogbo SCPZ ní Nàìjíríà. Fún SCPZ àti ABIR Ìpínlẹ̀ Kogi:<br>- Ríi dájú pé ìdàgbàsókè wà kí wọ́n sì pèsè àwọn ìlànà àti ìgbéléwọ̀n fún iṣẹ́ pípé lábẹ́ ABIR àti SCPZ;<br>- Wọ́n gbọ́dọ̀ darapọ̀ mọ́ bí gbogbo ètò nípa àlàkalẹ̀ fún àwọn olùdókòwò lábẹ́ SCPZ àti ABIR ṣẹ ń lọ. Bákan náà, wọn gbọ́dọ̀ ríi dájú pé wọ́n ṣiṣẹ́ ESIA/ESMP ní ìbámu pẹ̀lú òfin ìgbèríko àti òfin ààbò Báǹkì Àgbáyé |

| | | |
|---|---|---|
| | | - Ríi dájú pé SCPZ ti EMC pèsè ìjábọ̀ tó yẹ lórí ààbò fún okòwò tí a fẹ́ dáwọ̀lé;<br>- Yíyan òṣìṣẹ́ elétò ààbò àyíka àti àwùjọ tí ó kúnjúwọ̀n tí ó mọ̀ nípa iṣẹ́ yìí tí yóò sì lè bá àwọn àjọ tó wà lábẹ́ PMU ṣiṣẹ́ pọ̀ |
| 8 | Ìgbìmọ̀ Aṣàkóso Amúṣẹ́ṣe SCPZA (EMC) | - Àwọn EMC ń ṣojú fún SCPZA ní ẹlẹ́kùnjẹkùn, àwọn ni wọ́n sì ń darí ìmúṣẹ́ṣe olú èrò iṣẹ́ fún SCPZ. Bákan náà ni wọ́n ń darí iṣẹ́ ojoojúmọ́ lábẹ́ SCPZ àti APIR.<br>- Rírii dájú pé gbogbo àwọn olùdókòwò tẹ̀lé òfin àyíká àti àwùjọ gẹ́gẹ́ bí ó ti wà nínú ESMF yìí àti ti ohun-èlò ààbò tí a ó gbé kalẹ̀ ní ìbámu pẹ̀lú òfin orilẹ̀-èdè àti ti ìlànà ààbò Báńkì Àgbáyé<br>- Ṣiṣẹ́ pẹ̀lú àwọn PMU láti ríi dájú pé àgbéyẹ̀wò àṣàmọ̀ àbájáde ESIA/ESMP jinná kí wọ́n tó fi ṣọwọ́ sí FMENV àti Báńkì Àgbáyé<br>- Rírii dájú pé àwọn òfin àyíká àti àwùjọ hàn nínú gbogbo àkọsílẹ̀, ojúlówó iṣẹ́ àti àwọn amúgbálẹ́gbẹ̀ẹ́ lábẹ́ SCPZ àti ABIR |
| 9 | Báńkì Àgbáyé | - Pèsè ètò nípa títẹ̀lé òfin ààbò<br>- Yóò má ṣọ́ bí wọ́n ti ń tẹ̀lé òfin wọ̀nyí tó nípa iṣẹ́ òfínntótó<br>- Yóò máa ṣiṣẹ́ ọ̀fínntótó, ṣàgbéyẹ̀wò, ìfọnimọ̀ àti ìfàṣẹsí fún àwọn ESMF àti àwọn ohun-èlò pàtàkì mìíràn tí a gbé kalẹ̀ fún àwọn àmúgbálẹ́gbẹ̀ẹ́ iṣẹ́.<br>- Ṣíṣe àmójútó gbogbo ìgbà fún iṣẹ́ ESMF/ESMP, ṣiṣẹ́ àjọ amúṣẹ́yá pẹ̀lú ìfọwọ́kún ìmúṣẹ́ṣe ní gbogbo àkókò iṣẹ́, ṣàmójútó ìlọsíwájú iṣẹ.<br>- Pilẹ̀ àwọn ọ̀nà àgbàṣàkóso ìmúṣẹ́ṣe<br>- Pèsè ìfagbárafúnni fún àwọn tó bá yẹ |
| 10 | Ìjọba Ìbílẹ̀ | - Yan àwọn Òṣìṣẹ́ Àṣojú Ẹ̀ka Ìjọba Ìbílẹ̀ (LGDO) tí yóò máa ṣàbẹ̀wò sí àwọn agbègbè àti àwọn amojú-ẹ̀rọ APIR/SCPZ lóòrekóòrè láti lè mú ìdásí tó rinlẹ̀ wá àti láti jẹ́ kí wọ́n lè tẹ̀lé òfin àyíká tó de Ìjọba ìbílẹ̀ náà.<br>- Fọwọ́sowọ́pọ̀ pẹ̀lú àwọn PMU nípaa dídarapọ̀ mọ́ àyẹ̀wò fínnífínní àti ìfojúwòye ti àwùjọ àti àyíká tí a fi ń ṣòdiwọ̀n fún àwọn amúgbálẹ́gbẹ̀ẹ́ iṣẹ́ àti àgbéyẹ̀wò gbogbogbòò lórí iṣẹ́ ESIA àti ESMP |

| | | |
|---|---|---|
| 11 | Kọmití Àwọn Àgbẹ̀ Agbègbè (CFEC) | Èyí ti àwọn SCPZA ti EMC dá sílẹ̀<br>- CFEC yóò ríi dájú pé ètò-ọ̀gbìn ń gbóòrò síi,<br>- Yóò tọ́ka sí àwọn ibi tí a ti nílò ìdánilẹ́kọ̀ọ́ ní àwùjọ àti àyíká láti kin àwọn àgbẹ̀ lẹ́yìn,<br>- Darapọ̀ mọ́ àgbéyẹ̀wò àwọn ohun-èlò ààbò pẹ̀lú fífàyè gba ìdásí àwọn ará àwùjọ. |
| 12 | Àwọn Olùdókòwò àti Olùmúgbòòrò Ọjọ́ iwájú | - Tẹ̀lé àwọn ìlànà ESMF yìí àti àwọn ìlànà àti òfin àwùjọ àti àyíká mìíràn tó ṣe pàtàkì fún iṣẹ́ yìí kí ó lè máa lọ déédé<br>- Ìdásílẹ̀ abala ààbò tí a kàn nípá fún àmójútó gbogbo iṣẹ́ lọ́nà tí yóò fi tẹ́ gbogbo awọn tí ọ̀rọ̀ kàn lọ́rùn |
| 13 | Ọkọ̀ Iṣẹ́ Àkànṣe Ẹlẹ́kùnjẹkùn | - Àwọn iléeṣẹ́ ẹlẹ́kùnjẹkùn tí yóò máa ṣiṣẹ́ àkànṣe ní a ó gbékalẹ̀ tí wọn yóò sì máa ṣiṣẹ́ fún àwọn amojú-ẹ̀rọ lábẹ́ SCPZ àti ABIR<br>- Jẹ́ kí ìkópa àwọn ènìyàn agbègbè wà pẹ̀lú ìdánilójú pé gbogbo ìṣẹ̀lẹ̀ àwùjọ ń kàn wọ́n ní ìbámu pẹ̀lú àlàkalẹ̀ ESMF àti àwọn ohun-èlò ààbò tí a ó fi sínú ìmúṣẹ́ṣe nínú gbogbo ìmúdàgbàsókè àwọn àgbékalẹ̀ gbogbo. |
| 14 | Àwọn NGO/CSO/CDA | - Ṣe ìrànwọ́ nípa gbígbé ìgbéṣe ìdásí lórí àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ àyíká àti àwùjọ bí ó ti yẹ,<br>- Ṣíṣe ìwàdìí onímọ̀ sáyẹ́nsì pẹ̀lú àwọn ẹgbẹ́ ìjọba láti dá ọgbọ́n ìmúgbòòrò àti ìmúdàgbàsókè àwùjọ,<br>- Ṣíṣe ètò, dídarí àti rírii dájú pé àwọn èèyàn ń lo kẹ́míkà apakòkòrò bí ó ti yẹ nípa àlàkalẹ̀ ètò ìtanilólobó<br>- Pípesè ìrànlọ́wọ́ ńlá fún ètò ìṣàkóso, àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ tó jẹ mọ́ ìdarí, ìgbé-ayé àti àwọn mìíràn bẹ́ẹ̀, mímú ìdínkù bá ipa òdì tó lè jẹyọ nínú iṣẹ́ àti ìṣàbójútó. |

## *Ìfúnnilágbára àti Ìdánilẹ́kọ̀ọ́*

Nípa ìfọ̀rọ̀wérọ̀ àwọn ará àwùjọ, a ṣe àgbékalẹ̀ ìgbéléwọ̀n agbára ìmúṣẹ́ṣe iléeṣẹ́ Ìjọba Àpapọ̀ àti ti Ìjọba Ìpínlẹ̀, àwọn ẹ̀ka iléeṣẹ́ àti iléeṣẹ́ agbaṣẹ́ṣe (MDA) pẹ̀lú àwọn PMU náà. Àwọn ìṣòro tó ń dojú kọ ìlọdéédé iṣẹ́ àwọn MDA jẹ́ ìṣoro ajẹmọ́ ẹ̀kọ́ ìmọ̀-ẹ̀rọ àti àwọn ohun-èlò. Àwọn náà nìyí:

- Àìnímọ̀ kíkún lórí àjọṣepọ̀ tó wà láàárín ìlànà ààbò àjọ àgbáyé àti àwọn òfin àwùjọ àti àyíká ní Nàìjíríà;
- Àìsí kíkún ìfipámúni láti tẹ̀lé àwọn òfin ìmúdàgbàsókè;
- Àìsí ìmọ̀ kíkún lórí àwọn EIA àti Ìyẹ̀wé Àwùjọ àti Àyíká wò lásíkò ìkọ́lé àti àsìkò títún ojúnà àgbàrá ṣe;
- Àìsí ìmọ̀ kíkún lórí Ọgbọ́n Ìṣàgbéyẹ̀wò Àwùjọ àti Àyíká;
- Àìmójú tó bí omi ti dára sí, bí omi ti ń ṣàn sí àti àìsí ọgbọ́n tí a fi ń kó dátà jọ fún ìmọ̀ nípa omi;
- Àìsí agbára àti ìmọn-ọ́n-ṣeláti tọ́jú àwọn pàǹtí àfojúrí.

Kí àfojúsùn àwọn ESMF lè wá sí ìmúṣẹ, ó yẹ kí ìfúnnilágbara àti ìfagbára fún àwọn tó wà nídìí ìṣàkóso àwùjọ àti àyíká ní ipele àwọn MDA ti Ìjọba Àpapọ̀ àti ti Ìpínlẹ̀ ní Ìpínlẹ̀ Kogí di mí múṣẹ. Èyí gùn lé ìmúdàgbàsókè iléeṣẹ́, ìmúgbòòrò àwọn ààtò ìṣàkóso àti àwọn ọ̀nà àgbàmúṣẹ́ṣe gbogbo, kì í wá ń ṣẹ láàárín ibi iṣẹ́ yìí nìkan o, ó tún níí ṣe pẹ̀lúìṣàkóso ìbáṣepọ̀ láàárín iléeṣẹ́ tàbí ipele àwùjọ kan sí òmíràn.

Àwọn ohun ti ìṣàkóso àwùjọ àti àyíká pẹ̀lú ìpèsè inú ESMF ń fẹ́, ìmọ̀n-ọ́n-ṣe àti ìfúnnilágbára ni yóò wúlò ní àwọn agbègbè wọ̀nyí:

- Ọ̀nà Ìgbàṣàyẹ̀wò Ipa Àyíká – àgbéyèwò fínnífínní, ìfojúwòye, ìṣàtúpalẹ̀ ipa, ìgbésẹ̀ ìmúdínkù àti ìṣàmójútó, àgbéyẹ̀wò àwọn ìjábọ̀ ESIA;
- Ìsànwó Àwùjọ Déédé: Irú ìsànwó déédé, àyẹ̀wò fínnífínní iṣẹ́ fún àwọn gbèsè, ìfojúwòye ìtọpinpin ìsanwó déédé pẹ̀lú àgbéyẹ̀wò ìjábọ̀ ìsanwó déédé; àti
- Ìmójútó àti Ìgbéléwọ̀n – mímọ pàtàkì ìmójútó àti ìgbéléwọ̀n (M&E) nínú ṣíṣe iṣẹ́, àwọn ètọ́ M&E fún àyíká àti ìmúdúróṣinṣin àwọn iṣẹ́.

## Ètò Ìṣúná Àfojúbù ESMF fún Ìmúṣẹ́ṣe

Kí iṣẹ́ ìṣàkóso mímú ìdínkù bá ipa òdì láwùjọ àti àyíká labẹ́ ESMF lè bẹ́ṣẹ járí,ó yẹ kí ètò ìṣúná wà fún àwọn amúgbálẹ́gbẹ̀ẹ́ iṣẹ́. Ó yẹ kí a lè dá ibi tí a fẹ́ náwó sí mọ̀ bó tilẹ̀ wà ní kedere. Èyí yóò jẹ́ kí a mọ pàtàkì owó tí a fẹ́ ná, yóò sì jẹ́ kí a mọ bí a ó ti ṣètò rẹ̀ sílẹ̀ bí ó ti yẹ.

Lára ètò ìṣúná ànílọ́kàn fún ọ̀kọ̀ọ̀kan àwọn iṣẹ́ yìí ni owó mímú ìdínkù bá ipa òdì láwùjọ àti àyíká, owó ìṣàkóso, owó àmójútó àyíká àti ìfúnnilágbára. Gbogbo owó ìṣàkóso tí a ó ná lórí ESMF yìí ni yóò wá láti ara owó-ìná ti a ti yà sọ́tọ̀ fún iṣẹ́ yìí hàn.

Àtẹ ES e. ìsàlẹ̀ yìí fi ìlàkalẹ̀ ètò ìṣúná ìmúṣẹ́ṣe lórí ìsanwó déédé nínú iṣẹ́ yìí. Gbogbo owó-ìná tí iṣẹ́ yìí nílò ni a fojú bù sí N49.17m ($265,783.78).

| (Àtẹ ES e.) Ètò Ìṣúná Àfojúbù ESMF fún Ìmúṣése Lọ́dún Kan | | | |
|---|---|---|---|
| 1 | Àwọn Ẹ̀tọ́ ESMF | Ìpìlẹ̀ ètò ìṣúná àti àwọn èrò Ànílọ́kàn | Àpapọ̀ owó-ìná lọ́dún kan (₦) |
| 2 | Ìfagbára fún àwọn òṣìṣẹ́ PMU | Àwọn ètò ìdánilẹ́kọ̀ọ́ tí ó wáyé ní orílẹ̀-èdè yìí | ₦5M |
| | Àwọn ìpàdé, ìpàdé àkànṣe-iṣẹ́ àti ìpenisíṣẹ́ láàárín àwọn tí ọ̀rọ̀ kàn | Àfojúbù owó-ìná lóṣù jẹ́ ₦35,000 fún ẹnìkan lọ́nà mẹ́wàá bẹ́ẹ̀ lọ́dún kan | ₦4.2m (tí a bá fojú iye pàtó wò ó) |
| 3 | Ìṣàyẹ̀wò fínnífínní àyíká fún ètò-ìnáwó | Kò sí àfikún ètò-ìṣúná | Kò sí àfikún ètò-ìṣúná |
| | Pípe àwọn onímọ̀ àrà-ọ̀tọ̀ síṣẹ́ | A lè pe àwọn onímọ̀ àrà-ọ̀tọ̀ síṣẹ́ láti wá ṣe ìwádìí àwọn ọ̀rọ̀ tó sú yọ | Èyí yóò di mímọ̀ tí àkókò náà bá tó |
| | Lílọ sí gbọ̀gàn ibi-iṣẹ́ | Lílọ sí gbọ̀gàn ibi-iṣẹ́ fún òṣìṣẹ́ PMU méjì lọ́dún. Èyí san owó ọkọ̀, ilégbèé àti àláwańsì ojoojúmọ́ | ₦1.5m |
| | Àwọn ìpàdé, ìpàdé àkànṣe-iṣẹ́ àti ìpenisíṣẹ láàárín àwọn tí ọ̀rọ̀ kàn | Kò sí àfikún ètò-ìṣúná | Èyí wà lórí iye pàtó tí owó náà jẹ́ |
| 4 | Ìpàdé àkànṣe-iṣẹ́ lórí ìfojúwòye ti ESIA | Ìpàdé àkànṣe-iṣẹ́ lórí ìfojúwòye ti ESIA lọ́dun kan | Gẹ́gẹ́ bí a ti pèsè rẹ̀ nínú ESIA/EMP |
| | Ìjàbọ̀ pàtó ESIA fún amúgbálẹ́gbẹ̀ẹ́ iṣẹ́ | Yóò jẹ iye tí ESIA kọ̀ọ̀kan bá jẹ́, èyí wà lórí bí ó ti jìnnà tó | ₦20m |
| | Ìjàbọ̀ pàtó ESMP fún amúgbálẹ́gbẹ̀ẹ́ iṣẹ́ | | ₦12m |
| | Pípe àwọn òṣìṣẹ́ àrà-ọ̀tọ̀ lórí àwùjọ àti àyíká | | Gẹ́gẹ́ bí ìpèsè ESIA/ESMP |
| 5 | Ìfọkànsí ìṣàbójútó pẹ̀lú ESMP lórí ọ̀rọ̀ E&S lákòókò tí iṣẹ́ ò tíì bẹ̀rẹ̀ | Iṣẹ́ ibi yóò jẹ́ iṣẹ́ àbójútó olóṣù mẹ́rin-mẹ́rin tí wọn yóò ṣe láàárín ọjọ́ márùn-ún nínú oṣù mẹ́rin láàárínọdún kan | ₦2m |
| 6 | Ìfọkànsí ìṣàbójútó pẹ̀lú ESMP lórí ọ̀rọ̀ E&S lákòókò tí iṣẹ́ ti ń lọ lọ́wọ́ | Iṣẹ́ ibi yóò jẹ́ iṣẹ́ àbójútó olóṣù mẹ́rin-mẹ́rin tí wọn yóò ṣe láàárín ọjọ́ márùn-ún nínú oṣù mẹ́rin láàárín | Bí ó ti rí nínú wúnrẹ̀n karùn-ún |

| | | | |
|---|---|---|---|
| | | ọdún kan | |
| **7** | **Àròpọ̀ Àfojúbù Owó-Ìná** | | **₦44.7m** |
| **8** | **Nǹkan Àìròtẹ́lẹ̀** | **Ìdá mẹ́wàá Àròpọ̀ Alábọ́dé** | **₦4.47m** |
| | **Àròpọ̀ gbogbogbòò** | | **₦49.17m ($265,783.78)** |

**$1= ₦185**

***Ìfọ̀rọ̀lọ̀ àwọn tí ọ̀rọ̀ kàn***

Ní ìbámu pẹ̀lú òfin ààbò Báńkì Àgbáyé tí Isọ̀rí EA ti Iṣẹ́ A ń tẹ̀lé, ó hàn pé ìfọ̀rọ̀lọ̀ àwọn tí ọ̀rọ̀ kàn ṣe pàtàkì nínú SCPZ àti nínú ètò EA.

Àwọn èròǹgbà ìfọ̀rọ̀lọ̀ náà ni láti:

- Fí tó àwọn àwùjọ tí ọ̀rọ̀ náà kàn tí wọ́n wà ní agbègbè ibi iṣẹ́ ABIR léti nípa èròǹgbà ìmúdàgbàsókè iṣẹ́;
- Fún wọn ní àyè láti so èrò ọkàn wọn nípa ipa tí iṣẹ́ náà yóò ní;
- Gba dátà/ọ̀nà àbáyọ láti agbègbè náà tí yóò wúlò fún ìpàjùbà iṣẹ́ ESMF/ESMP/ESIA (bí àpẹẹrẹ ọ̀nà iparí aáwọ̀ alábẹ́lé);
- Ṣe àgbékalẹ̀ ọ̀nà tó yẹ láti yàgò fún tàbí mú ìdínkù bá àwọn ipa òdì tí ó lè yọjú lẹ́nu iṣẹ́ àti ìpèsè ọ̀nà láti ṣàtúnṣe fún ẹnikẹ́ni tí ọ̀rọ̀ yí bá kàn.
- Fún ohùn wọn ní agbára nípa fífi àyè gba èrò àti àbá wọn wọlé sínú àlàkalẹ̀ àbá ìmúṣẹṣe ESMF/ESIA.

***Ọgbọ́n ìdánimọ̀ àti ìpenisísẹ́ fún àwọn tí ọ̀rọ̀ kàn***

Ọ̀nà méjì gbòógì ni àwọn tí ọ̀rọ̀ kàn pín sí: (1) àwọn tí ipa òdì tàbí ipa rere iṣẹ́ yìí yóò kan léyìí tí ó kan àwọn tí yóò pàdánù ilẹ̀, oko, oko ìjẹ fún ẹran, ilé, nǹkan ọ̀gbìn, igi owó, òwò wọn, abbl pẹ̀lú (2) àwọn tí yóò ran iṣẹ́ lọ́wọ́ pẹ̀lú dátà, agbára àti ní àwọn ọ̀nà mìíràn tí wọ́n ti lè fi ìmọn-ọ́n-ṣe wọn hàn kí iṣẹ́ tó bẹ̀rẹ̀ àti nígbà tí iṣẹ́ bá ń lọ lọ́wọ́ (FADAMA, Ẹ̀ka Iléeṣẹ́ àti Ẹ̀ka Iléeṣẹ́-Agbaṣẹ́ṣe Ìjọba).

A gba ìdámọ̀ ẹ̀ka iléeṣẹ́-agbaṣẹ́ṣe ìjọba àti ipa láti ọwọ́ àwọn oníbààrà àti èròjà ìtanilólobó bí ó ti wà nínú àkọsílẹ̀ àgbéyẹ̀wò iṣẹ́. Bí a ti dá àwọn tí ọ̀rọ̀ kàn jù mọ̀ ni ó wà nísàlẹ̀ yìí:

- Mímọ agbègbè ìjọba ìbílẹ̀ láàárín ìyípo ọgbọ̀n Kìlómítà káàkiri agbègbè SCPZ (pẹ̀lú ìrànlọ́wọ́ sátáláítì àti ìmọ GIS);
- Lílọ sí olú iléeṣẹ́ ìjọba ìbílẹ̀ - ṣíṣe ìpàdé pẹ̀lú alága ìjọba ìbílẹ̀ àti aṣojú ẹ̀ka ètò-ọ̀gbìn pẹ̀lú àwọn òṣìṣẹ́ FADAMA;
- Ìpàdé pẹ̀lú àwọn olórí ìletò àti àwọn olórí ìlú;

- Ìpádé àti àpérò pẹ̀lú àwọn ẹgbẹ́ kékèèké tí kò ta yọ ẹgbẹ́ àwọn obìnrin, àgbẹ̀, darandaran àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ.

Ìfọ̀rọ̀lọ̀ yìí ni a là kalẹ̀ sí Àtẹ ES f. tí a mọ̀ sí àtẹ èyí tí kò dáwọ́ dúró nínú ìyípo lórí iṣẹ yìí. Ó bẹ̀rẹ̀ ní Ọjọ́ Kẹtàlá Oṣù Kẹjọ, Ọdún2014, ó sì tẹ̀ síwájú di Ọjọ́ Kẹrìnlélógun, Oṣù Kẹjọ fún abala àkọ́kọ́ tí ó jẹ́ ti àwọn ìjọba tí ọ̀rọ̀ kàn àti àwọn ará ìlú tí wọ́n ń gbé ní agbègbè ojú iṣẹ́ SCPZ fún ìpèsè ohun-èlò ààbò.

Abala kejì ni ó yẹ kí a papọ̀ mọ́ iṣẹ́ FMARD ti Báńkì Àgbáyé tí ó wáyé láti Ọjọ́ Kẹtàlá Oṣù Kẹwàá, Ọdún 2014, tí ó sì pèsè ọ̀nà láti fìdí dátà tí a ní tẹ́lẹ̀ múlẹ̀. Bákan náà ni ó mú kí ìfọrọ̀wérọ̀ pẹ̀lú àwọn tí ọ̀rọ̀ kàn rinlẹ̀, ní pàtàkì Ẹ̀ka Iléeṣẹ́ Ìjọba Abójútó Ọ̀rọ Àyíká, Abójútó Ọ̀rọ̀ Aginjù abbl lórí àwọn iṣẹ́ tí ó kan ètò ààbò.

Abala kẹta ìfọ̀rọ̀lọ̀ ni ipele tí ó kó Agbègbè Ìjọba Ìbílẹ̀ mẹ́rin mọ́ra, pẹ̀lú àwọn ẹgbẹ́ àti ìletò tí ọ̀rọ̀ iṣẹ́ yìí kàn láàárín 280,000Ha ti agbègbè ABIR láti Ọjọ́ Kẹtàdínlọ́gbọ̀n sí Ọjọ́ Kẹta Oṣù Kọkànlá, Ọdún 2014. Àwọn ìletò àti Agbègbè Ìjọba Ìbílẹ̀ tí a dé náà ni Iwaa àti Ọshokosho ní LGA ti Lọkọja, Iresuare/Ọsara-Gada ní LGA ti Adavi, Ohu àti Irukura ni LGA ti Okehi àti Ìyàrà ní LGA ti Ìjùmú.

| Àtẹ ES f: | Akọsílẹ̀ Ìfọ̀rọ̀lọ̀ | | |
|---|---|---|---|
| LGA | Ibùdó | Àwọn Ẹgbẹ́ tí a dá mọ̀/fọ̀rọ̀lọ̀ | Déètì |
| Kabba-Bunu | Odo-Ape, Kabba, Agbadu, Eshi, Ilegun, Oyo | Àwọn olórí ìletò, àwọn àgbẹ̀ obìnrin, ìletò àwọn Fulani, Ìletò àwọn Èbìrà, ẹgbẹ́ àwọn ọdẹ, àwọn ọ̀dọ́ | 11th -19th Oṣù Kẹjọ, 2014, 14th - 15th Oṣ̀ù Kẹ́wàá, 2014 |
| Lọkọja | Obajana, Oshokosho, Iwaa | Bíi ti tòkè | 7th -10th Oṣù Kẹjọ 2014, 27th Oṣù Kẹwàá, 2014 |
| Adavi | Iresuare/Osara Ngada | Àwọn olorí ìletò, àwọn àgbẹ̀,ẹgbẹ FADAMA, àwọn obìnrin, ìletò àwọn Fúlàní, àwọn ọ̀dọ́ | 28thOṣù Kẹwàá – 3rd Oṣ̀ù Kọkànlá, 2014 |
| Ijumu | Ayegunlẹ àti Aiye | Àwọn olorí ìletò, Alága LGA Ìjùmú, àwọn àgbẹ̀ ẹgbẹ FADAMA, àwọn obìnrin, ìletò àwọn Fúlàní, àwọn ọ̀dọ́ | 28th Oṣù Kẹwàá – 3rd Oṣ̀ù Kọkànlá, 2014 |
| Okehi | Irukuochakoko, Irukura, Ohu | Àwọn olorí ìletò, àwọn àgbẹ̀ ẹgbẹ FADAMA, àwọn obìnrin, ìletò àwọn Fulani, àwọn ọ̀dọ́ | 28th Oṣù Kẹwàá – 3rd Oṣ̀ù Kọkànlá, 2014 |

***Àwọn Èrè Ìfọ̀rọ̀lọ̀***

Èròǹgbà ìdàgbàsókè iṣẹ́ náà, bí ó ti pọ̀ tó àti àwọn ọ̀rọ̀ lórí ààbò ni a jẹ́ kó di mímọ̀ fún àwọn tí ọ̀rọ̀ kàn àti àwọn àwùjọ tí ó wà ní agbègbè tí a bẹ̀ wò láti lè jẹ́ kí ìdásí tó péye wà.  Àbájáde ìfọ̀rọ̀lọ̀ yìí jọra nípa ìbéèrè àti àfojúsùn àwọn èèyàn. Ìjọra púpọ̀ tún wà láàárín àwọn tí ọ̀rọ̀ kàn, ìgbé-ayé wọn àti ipò ọrọ̀-ajé wọn láwùjọ.

Ìfọ̀rọ̀lọ̀ pẹ̀lú àwọn ẹ̀ka iléeṣẹ́-agbaṣẹ́ṣẹ ìjọba jẹ́ ọ̀nà láti jíròrò lórí àwọn òrọ̀ tó ṣe pàtàkì bíi agbáraẹ̀ka iléeṣẹ́-agbaṣẹ́ṣẹ, ìdásí iṣẹ́ SCPZ, iṣẹ́ àti ìṣe, àjọlò ọgbọ́n ìmúṣẹ́ṣẹ tí ó jẹ jáde láti ara iṣẹ́ tí wọ́n ti ṣẹ sẹ́yìn tó sì lè ṣe iṣẹ́ yìí láǹfààní nípa ìlànà iṣẹ́ àwọn tí ọ̀rọ̀ kàn tí yóò sì jẹ́ kí wọ́n ṣe iṣẹ́ wọn bí iṣẹ́ ní gbogbo ìgbà. Àbájde ìfọ̀rọ̀lọ̀ àwọn tí ọ̀rọ̀ kàn nìwọ̀nyí:

- Rírí àwọn àwùjọ tí ó jọ pé a ti kọ̀ tì ní àwọn agbègbè yìí;
- Ìdí àmúlò ẹ̀rọ ayé òde-òní tó sì bóde mu kí a lè yàgò fún bíba àwùjọ jẹ́;
- Dída pàǹtí nù lọ́nà tó tọ́;
- Bí ìjọba ti máa ń gba ilẹ̀ fún lílò àti ètò ìlolẹ̀ tó wà ní Ìpínlẹ̀ Kogí;
- Kí lo máa ṣẹlẹ̀ sí àwon darandaran tí wọ́n ń lo apákan ilẹ̀ náa gẹ́gẹ́ bí oko ìjẹ fún ẹran wọn?
- Ìgbà wo ni iṣẹ́ náà yóò bẹ̀rẹ̀?
- Ǹjẹ́ wọn yóò pín àwọn ilé náà dáadáa láàárín àwọn agbègbè náà?
- Ó yẹ kí wọ́n kọ́ àwọn ilé náà síbi tó sún mọ́ àwọn èèyàn kí wọ́n le jèrè rẹ̀ lọ́pọ̀ yanturu;
- Àwọn ará agbègbè náà yẹ ní gbígbà sí iṣẹ́, kí a fún wọn ní ìdánilẹ́kọ̀ọ́ àti àwọn àǹfààní mìíràn tí iṣẹ́ yìí yóò mú wá.

***Bí ọ̀pọ̀ ènìyàn ti rí iṣẹ́ yìí sí***

Lápapọ̀, nípa bí àwọn èèyàn ti rí iṣẹ́ yìí sí, ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn ènìyàn ni ó fọwọ́ sí ìtẹ̀síwájú iṣẹ́ yìí nínú àwọn ẹgbẹ́ tí a bá ṣe ìpàdé. Inú àwọn àgbẹ̀, ọ̀dọ́, obìnrin àti àwọn adaran Fulani dùn pé a fọ̀rọ̀ lọ̀ wọ́n wọ́n sì sọ bí àwọn ti nírètí pé iṣẹ́ yìí yóò ṣe mú ìgbé-ayé wọn dára tó. Ní Alape, Kabba-Bunu àti Oshokosho, Lọkọja inú àwọn lọ́balọ́ba dùn sí ìlànà ìfọ̀rọ̀lọ̀ yìí wọ́n sì sọ pé àwọn kò tíì rí i rí kí wọ́n ṣe ìfọ̀rọ̀lọ̀ ńlá báyìí; ó sì dá wọn lójú pé àwọn alákòóso yóò mú ìlérí wọn ṣẹ fún ẹnikẹ́ni tó bá pàdánù ohun ìní rẹ̀. Àwọn agbègbè mìíràn bíi Adavi, Okehi àti Ijumu ò to mọ púpọ̀ ípa iṣẹ́ náà tẹ́lẹ̀ àmọ́ inú wọn dùn láti darapọ̀ mọ́ iṣẹ́ náà torí wọ́n gbà pé yóò pé fún wọn.

Ìfọ̀rọ̀lọ̀ tó bẹ̀rẹ̀ nígbà tí à ń pilẹ̀ iṣẹ́ yìí yóò tún tẹ̀ síwájú di àkókò ìmúṣẹ́ṣe. Títí di àkókò yìí, àwọn aṣojú yóò pèsè àwọn ohun èlò tó yẹ ní kánmọ́kánmọ́ fún ìfọ̀rọ̀lọ̀ ní ọ̀nà tí ètò àti èdè rẹ̀ yóò fi yé àwọn ẹgbẹ́ tí afọ̀rọ̀lọ̀ yékéyéké.

Ìṣíṣọlójú ọ̀rọ̀

A ṣe àgbékalẹ̀ ESMF náà pẹ̀lú ìfọ̀rọ̀lọ̀ PMU ti ìpele Ìjọba Àpapọ̀, àwọn MDA ti ìpínlẹ̀, àwọn CBO/NGO àti àwọn ẹgbẹ́ àwùjọ mìíràn. A ó ṣíṣọ lójú EMSF náà ní gbàgede gẹ́gẹ́ bí ìwé adádúró tó wà fún àyẹ̀wò àti ìdásọ́rọ̀ Ìjọba Àpapọ̀/Ìpínlẹ̀, Iléeṣẹ́ Ìjọba Amójútó Ọ̀rọ̀ Àyíká. Èyí ni yóò wáyé ní àwọn agbègbè tí a yàn pẹ̀lú Ìjọba Àpapọ̀, Ìpínlẹ̀ Kogi àti àwọn Ìjọba Ìbílẹ̀, pẹ̀lú àwọn ilé ìfọrọ̀tónilétí ti Báńkì Àgbáyé. Àwọn EIA/EMP ti oníkálukú ni a ó ṣe létò fún iṣẹ́ àkànṣẹ alábọ́dé kọ̀ọ̀kan ní ìbámu pẹ̀lú ìlànà tí ó wà nínú ESMF yìí, a ó sì máa ṣíṣọ lójú wọn bákan náà.